# Ọlọ́run Ìran Búburú Yìí

Jeffersonville, Indiana USA

Owurọ Ọjọ Kin-In-Ni, Osu Kẹjọ, Ọdu

1 [Arakunrin Neville ka awọn Ìpinnu Ìgbìmọ̀ Ijọ. Edited]

2 Ohun gbogbo lo seese……

Saa ti gbagbọ, Saa ti gbagbọ

Ohun gbogbo lo seese…… Saa ti…

Ẹ jẹ ki a tẹriba. Baba wa Ọrun, awa dupẹ ni owurọ yii, pe a lee gbagbọ. Iwọ ti jẹ ki eyi seese nipa ẹjẹ Ọmọ Rẹ Jesu ti a ta silẹ, ki awa ba lee jẹ alabapin Ore-Ọfẹ Rẹ. Ki a si di ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun, nipasẹ igbọran Rẹ titi de iku ori agbelebu, ti a si dawalare nipa igbagbọ ninu Rẹ ati ajinde Rẹ, ati nisisinyi, a ti tu Ẹmi-Mimọ si inu ọkan wa.

A dupẹ fun anfaani lati wa si ibí yii ni owurọ yii lati wa fi èrò wa ati iyin Ọlọrun han, eyi ti a n fiihan nipa awọn orin, ẹri, nipa Sáámù; kika Ọrọ Rẹ ati diduro de Ẹmi Mimọ tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ lati jẹ Isẹ Iransẹ ti a yan fun wakati yii. Fifun wa Oluwa. Jẹ ki a ri ibukun wíwá wa si ìhín loni gba. Nigba ti a ba si kuro ni ile isin yii, jẹ ki a lee sọ bi awọn ara ti o n ti Emahusi bọ wipe, “Njẹ ọkan wa ko ha gbọgbẹ ninu wa nigba ti O n bawa sọrọ ni owurọ yii?” Fun wa ni nkan wọnyi, Ọlọrun Ainipẹkun, ni Orukọ Jesu Kristi. Amin.

Ẹ joko.

Ẹ kaarọ ẹyin ọrẹ, nihin ninu ile isin, lọhun ati si gbogbo awọn ọrẹ wa kaakiri orilẹ ede yii. Lati gbogbo eti okun ni Iwọ oorun de gbogbo eti okun ni Ila oorun, titi de ariwa ati guusu, ni gbogbo ibi ti a so pọ mọra nipa ẹrọ ibanisọrọ.

O jẹ ọjọ ti o dara, nihin ni Ipinlẹ Indiana. Ìkúúkùu diẹ wa, ara tutu, o si dara pupọ. Inu ile isin kun akunfaya, ni gbogbo ẹgbẹ ogiri titi de gbogbo ode. A wa ni ifojusona nla ni ireti pe Oluwa yoo bẹ wa wo loni. A si lero wi pe, Ọlọrun ti fun un yin ni ọjọ didan nibikibi ti ẹyin wa. Ọjọ ti o dára sì ni, nitori Oluwa ti fi fun wa. Bi o ti wu ki oju ọjọ ri, ọjọ ti o dara ni. Inu wa dun lati wa nibi, paapaa nitori pe, a ni anfaani lati fi igbagbọ wa ninu Jesu Kristi han faye. A si fẹ lo anfaani kọọkan ti a ni lati fi ifẹ Ẹ Rẹ ati ohun ti O ti se fun wa han faye ri.

Loni awa……..

3 Ni isẹju diẹ sẹyin, a fun mi ni ifilọ kan lati se. Lẹhin naa, mo ni awọn nkan diẹ nihin ti mo fẹ sọ. Ọkan ninu wọn, ifilọ naa ti a fun mi si jẹ, nipa ipade igbimọ ti alẹ ijelo. Ọkan ninu awọn diakoni ijọ yi si ti ko lọ si Arizona lati maa gbe. Eyi si ni Arakunrin Collins, arakunrin wa ọwọn. Nigba ti o si wa lọhun, igbimọ ti yan Arakunrin Charlie Cox lati gba ipo rẹ nigba ti ko si nile, Igbimọ awọn Diakoni si ti yan Arakunrin Chalie Cox si ipo lati gba ipo isẹ Arakunrin Collins nigba ti ko si nile.

4 Ohun kan ti mo si tun fẹẹ sọ lẹẹkan si, mo fẹ dupẹ lọwọ gbogbo yin, (nitori pe awọn kan ninu yin ti lee lọ sile saaju isin iwosan lalẹ oni) fun awọn ẹbun daradara kekeke ati awọn nkan ti ẹ fun mi. Ẹ ti fun wa ni onjẹ pupọ lati igba ti a ti de sihin. Lati ọdọ mi, iyawo mi ati ẹbi mi, dajudaju a mọn riri eleyi. Nigba miiran mo maa n gbagbe lati sọ nkankan nipa rẹ. Se ẹ mọ pe oju kodi pupọ. Ọkan mi kun fun orisirisi nkan ni gbogbo igba. Ẹ tilẹ lee roo wo bi o se ri nipa ọpọ eniyan, kii se lati ijọ yii nikan, sugbọn lati gbogbo agbaye. Se ẹ rii? Eyi si n mu ki ọkan ero mi kun ni gbogbo igba.

Ẹnikan nsọrọ nipa, yiya awọn ọmọ si mimọ, isin itẹbomi ati bẹẹbẹẹ lọ. Iyẹn dara pupọ. O wumi kin lee see, sugbọn orisirisi nkan la ni lati se, emi ko ni asiko to. Mo ni lati fi ọkan mi si eleyi taara, eyi ni Isẹ Iransẹ ti a fi ran mi. Ẹ mọn pe, Bibeli sọ fun awọn Aposteli tabi Awọn Aposteli ninu Bibeli sọ wipe, “Ẹ wa laarin ara yin, awọn ọkunrin olorukọ rere, olootọ ti o kun fun Ẹmi Mimọ, ki wọn lee bojuto awọn isẹ naa. Mo si sọ fun Billy…..

O wipe, “Baba mi, se iwọ yoo ya awọn ọmọ ọwọ si mimọ ni akoko yii?”

Mo wipe, Aaaaa.“ Se ẹ rii? A ni pupọ wọn ti o n duro de iya-si-mimọ, otitọ si ni. Mo ni lati pada wa ki n wa fi ọjọ kan pato se iya-si-mimọ awọn ọmọ ọwọ. Nitori naa, o wumi lati se e bayii.

5 Sugbọn a fẹ dupẹ lọwọ olukuluku yin lati inu ọkan wa; iyawo mi, emi ati ẹbi mi. Awọn kan ko ounjẹ inu agolo wa fun wa, awọn ere tutu, wọta-mẹ́lónù, kántálúúpù, sítíróbírì, ohunkohun ti ẹ tilẹ lee ro nipa rẹ, wọn ko wọn wa fun wa.

Arakunrin ọwọn kan ati arabinrin rẹ ni ijelo, gbe tolotolo nla kan wa fun wa. Mo si n jẹ lọwọ. Mo ro wi pe mo ni lati pari rẹ ki n tolọ, bi n ko baa lee jẹ tan iyawo mi yoo gbe e lọwọ pẹlu wa. Nitori naa a mọn riri awọn

nkan wọnyii. Mo mọn ọpọlọpọ awọn eniyan naa, emi ko mọn diẹ ninu wọn. Wọn yoo ti gbe onjẹ naa si ẹnu ọna ile ki a to de. Nitori naa dajudaju mo mọn rírì i rẹ̀. Mo mọn ọpọ wọn, mo ti ri ọpọlọpọ, ọpọlọpọ si wa ti n ko rii. O da mi loju pe gbogbo yin ni mo si fẹ de ọdọ olukuluku yin, sugbọn ẹnikan soso ni mi. Se ẹ rii? N ko lee de ọdọ gbogbo eniyan. Mo n se ohun gbogbo ti mo mọn lati se.

6 Nitori naa, ki Ọlọrun wa pẹlu yin. O da mi loju pe, Ẹni kan wa ti yoo wa pẹlu yin. Eyi ni Jesu Kristi, O si lee see. Oun nikan naa ti O le wa nibi gbogbo nigba kan naa. O si tun lee se ohun gbogbo, nitori naa O le ba gbogbo aini wa pade.

Mo fi olukuluku yin le E lọwọ pe, Emi ki yoo….. mo ti n se bi mo se lee yara to lati igba ti mo ti debi lowurọ yii, emi yoo si ri olukuluku ti mo ba lee ri. Eyi ti emi ba si se alai ri, Ọlọrun ti o ni gbogbo Agbara, yoo ba gbogbo aini yin pade gẹgẹbi Ọrọ̀ Rẹ ninu ogo.

Emi ko lee ka eyi daadaa. Se o lee kaa? O jẹ Ifilọ Pataki kan. Mo si ro pe Billy ni o kọọ. Oun ri bi emi, nko tilẹ lee ka iwe ti mo kọ funrara mi. Nitori naa, mo ni awọn ọna ti mo ngba kọ akekuro-ọrọ lati kọ ohun ti mo fẹ silẹ. Bi iwọ ba si ri bi mo se kọ ohun ti mo fẹ waasu sihin. Iwọ ro wi pe, iwọ lee ka eyi? Mo ni ohun kan bi iranwọ ti o n rin ori afara kan kọja ati bẹẹbẹẹ lọ. [Arakunrin Branham ka ifilọ kan. Ed.] O dara.

7 Ohun miiran ti mo fẹẹ filọ bayii nipe, isin iwosan yoo wa ni alẹ yi. A o gbadura fun awọn alaisan. Nitori naa, mo lero pe iwọ yoo wa nibi.

A si ran ikini si gbogbo awọn eniyan ni gbogbo ibi, ni Orukọ Oluwa wa Jesu Kristi, pe ki Ọlọrun ki o bukun yin lowurọ yii. Awọn kan ninu yin ti fẹrẹ de agogo mejila ọsan bayi. Ati ni Arizona, ni bebe okun Iwọ oorun, nkan bi agogo meje owurọ ni. Nihin, awa si wa laarin awọn mejeeji. Nitori naa, ki Ọlọrun bukun yin bi ẹ ti n fetisilẹ bayi.

Emi ti fi eleyi sọkan mi lati igbati mo ti wa nibi.

8 Wọn ko si gba mi laaye lati lo gbọ̀ngàn wọ̀n-ọn-nì, Nigbẹyin, wọn gba pe a lee lo fun ipade kan sugbọn a ko gbọdọ gbadura fun awọn alaisan. Emi ko le se yẹn. Isẹ Iriju-Iwaasu mi niyẹn. Mo ni lati se ohun ti Ẹmi Mimọ ba sọ fun mi pe ki a se. Se o rii? Nitori naa, mo ro wi pe a lee farada ọjọ kan si ninu agọ yii. Ọju ọjọ si tutu lowurọ yii. Oluwa ti fun wa ni ọjọ to dara nihin, nitori naa, a dupẹ.

9 Bayi, ni sise eleyi, Mo ti wa sihin pẹlu ero lati waasu awọn Ìyọnu to gbẹhin, awọn Ìyọnu meje to gbẹyin, ati awọn Ipè meje to gbẹyin ati awọn Àrá meje ti Iwe Ifihan, ki a le sowọn papọ ni wakati ti a n gbenu rẹ yii, ki o le tẹle sisipaya awọn Edidi meje ati Igba Ijọ meje. Nitori naa, a ko lee ri aye lati see. Mo nireti pe, bi a ba se lee tete ri aye to fun eyi, yala nihin tabi ni Louisville, New Albany. Tabi ki a gbe àtíbàbà kan kalẹ, ki a lee kuku duro pẹ to bi Oluwa ba se dari wa lati se.

Sugbọn ninu eleyi(iwaasu yi) bayi, mo n lo anfaani yii lati sọ fun awọn eniyan nipa igbagbọ mi ninu Ọlọrun, ki n si mu yin wa si wakati ti a n gbe ninu rẹ yii. Ati nipa eyi, a ko sọọ nipa ẹnikan pato tabi awọn ẹkọ adamọ ohunkohun ti o lee jẹ, o kan saa jẹ gẹgẹbi Ọrọ Ọlọrun se ye mi ni. Ni ọjọ aiku to kọja, a si ni Itusilẹ Ẹmi Mimọ lori Ọrọ Ọlọrun. A lo akoko to pọ, emi ko tilẹ nifẹ bi a se pẹ to yẹn; sugbọn awa ko mọn igba ti a o pade fun igba ti o gbẹyin. A si fẹ se ohun gbogbo ti a ba lee se. Mo si fẹ se bi Pọọlu ti sọ wi pe, “Emi ko kuna lati sọ di mimọ fun yin, gbogbo Igbimọ Ọlọrun.” Jesu sọ wipe, Oun ko fi ohunkohun pamọ fun awọn ọmọ ẹhin Rẹ. Ati bi ọwọ́ mi si ti dí pupọ pẹlu igbiyanju mi lati duro si abẹ imisi Ẹmi Mimọ, lati wárí, ohun ti Ọrọ Ọlọrun fun wakati yii jẹ, nigba miiran, emi maa n kuna lati jade lọ se ojuse mi gẹgẹ bi iransẹ Kristi ati Oniwaasu. Sugbọn emi ti ni ọpọlọpọ arakunrin ti wọn n gbiyanju lati ranmilọwọ nipa eleyi, mo si dupẹ fun gbogbo awọn oniwaasu arakunrin mi.

10 Bayi, emi ko ni lọkan lati da ẹyin eniyan duro pẹ. Bi ẹyin ti ẹ wa nibomiran ti Ọrọ Ọlọrun yii n jade lọ si lowurọ yii, ba le wo inu ile isin yii lowurọ yii, ki ẹ si ri bi awọn eniyan to wa sihin se pọ yika gbogbo inu ile isin, titi de alafo ti awọn eniyan ma n gba kọja, gbogbo iyẹwu itọju awọn ọmọ ọwọ, ayika ode, titi de inu ọkọ bọọsi, ati ọkọ ajagbe ati nipasẹ redio ati bẹẹbẹẹ lọ, ẹ o o mọn isoro ti a ni. Ati ni isin kọọkan, ti ọpọ n kọja lọ ti wọn si n pè wi pe, wọn ko ri aye wọ inu ile isin. A si nilo aye si, ki awọn eniyan lee joko, ki ara si tu wọn. Ati fun mi lati mu isẹ iransẹ ti mo gbagbọ pe o se pataki pupọ wa, mo fẹ ki awọn eniyan lee farabalẹ joko gbọ Ọrọ Ọlọrun naa pẹlu iwe, kalamu ati Bibeli lati kọ Ọrọ naa silẹ. Sugbọn lọna yi, mo lero lati pada lọ wo akoko ti a n gbenu rẹ yii, ki n si mu awọn nkan ti ẹ o o ba pade wa. Ẹ o o si nilo wọn.

11 Bi mo ba wa sibi loni, tabi ni ọjọkọjọ tabi oniwaasu miiran ti mo si gbiyanju lati mu iwaasu kan wa fun awọn ẹni kiku ti a jẹ yii, ti akoko si ti sunmọle tan bayii, gẹgẹ bi emi se gbagbọ fun ọjọ oni, emi yoo jẹ alagabagebe bi mo ba gbiyanju lati waasu ohun kan ti inu yin yoo dun si sugbọn ti o lodi si Ọrọ Ọlọrun tabi ohun kan lati ko ero jọ tabi ohun kan bẹẹ, emi ko ni jẹ ohun ti mo wa nibi lati jẹ, eyi ni ni iransẹ Kristi. Mọ fẹ mu ohun kan tọ yin wa ti mo ro pe o se pataki si yin. Kii se ki a baa lee ri mi, sugbọn ohun to jẹ pe, bi mo ba

ku loni, ohun ti mo sọ yii, yoo fun ọkan yin ni idakọro lati lọ sin Ọlọrun.

12 Bayi, mo fẹ sọ wi pe, ohun kan wa ti o fẹ sẹlẹ laipẹ. Mo mọn ọn. Ọpọlọpọ yin ni ẹ ranti nigba ti Arakunrin Junior Jackson tọ mi wa nigba ti o ku diẹ ki n lọ si Arizona, nipa ala kan ti o la. Ohun to sajeji kan! Ẹyin melo ni ranti eleyii? Oluwa si fun wa ni itumọ rẹ, o si sẹlẹ bẹẹ gẹgẹ. Bayi o ti la ala miiran, ohun kan.

Ohun ajeji kan si sẹlẹ, okunrin kan wa sibi ni ijelo lati Oregon. Tipatipa lo tilẹ fi mọmi, o la ala kan na ti Arakunrin Jackson la, o si wa sọọ fun mi. Emi ko mọn itumọ rẹ, mo n duro de Oluwa. Sugbọn mo mọn wipe, yoo jẹ ohun kan lati ọdọ Ọlọrun. Saa ranti eyii. Bayii ni Oluwa wi ni. O jẹ ohun kan ti o ti ọdọ Ọlọrun wa. Emi ko mọn ohun ti o jẹ. Ohun kan pataki ni, o se pataki gidi! Lotitọ gan an, ni ibamu pẹlu ala ti awọn okunrin mejeji la, ọkan ninu wọn tilẹ lee jẹ ọmọ ijọ Baptisti, tabi Pirẹsibiteria. O see se ki o joko ninu isin yii ni owurọ yii. Emi ko mọn. O wa nibi ni ijelo. Emi ko mọn okunrin naa.

Sugbọn o sọ ala naa, pẹlu omije ni oju rẹ. Ọrọ yi tilẹ mu ki o wariri. O wa lati Oregon si ibi yii lati sọọ. Arakunrin Jackson si wa ni owurọ yii, bẹẹ gẹgẹ. Okunrin kan ko si mọn ekeji, ẹgbẹgbẹrun ibusọ laarin ibugbe wọn. Ala mejeeji si wa lori ohun kan naa. Nitori naa, Ẹmi Mimọ n fi itumọ rẹ pamọ fun mi. Emi ko mọn ohun ti n o o sọ fun okunrin naa. Sugbọn mo mọn pe Ọlọrun n gbaradi lati se ohun kan, yoo si logo loju wa.

13 Bayi, Iwaasu Ọrọ Ọlọrun ti owurọ yii, mo fẹ ka lati inu iwe Galatia. Emi ki yoo waasu, Ile ẹkọ ọjọ isinmi ni. Bayii, ẹyin okunrin ati obinrin ti ẹ wa ni iduro ni ẹgbẹgbẹ ogiri, bi ẹnikẹni ba fẹ dide lati gba yin laaye lati joko, eyi ko ni da mi laamu rara, ẹ saa se tọwọtọwọ. Eyin iyalọmọ bi ọmọ yin ba ke, ẹnikan yoo jade fun yin lati iyara ti a tii tọju awọn ọmọde, ki ẹ lee tọju ọmọ naa.

Bayi, mu kalamu rẹ, Bibeli, ki o si se tan lati kọ awọn Iwe Mimọ ti a o ka silẹ. Emi ko fẹ ki ẹ ni inira kankan. Mo fẹ ki ẹ wa ni ominira, lati joko kẹkọ. Bi ẹ ba si tako ohun kan, iyẹn dara. Sugbọn emi n sọrọ si gbogbo orile-ede ni owurọ yii, ki awọn eniyan ti o ti gba Isẹ Iransẹ ti Jesu Oluwa fifun mi fun akoko yi gbọ, ki wọn lee mọn ohun to ti sẹlẹ, ki wọn si lee ri i ninu Iwe Mimọ.

14 Ni ọjọ isinmi to kọja, a sọrọ lori "Awọn Ẹni Amin Ororo Ni Opin Aye" Bi ẹnikẹni ninu yin ba maa n feti si ohùn ti a gba silẹ, rii daju pe o feti si iwaasu yẹn. Kii se wi pe a fẹ ta ohun ti a gba silẹ, iyẹn kọ ni erongba wa. Erongba wa ni pe ki Ọrọ Ọlọrun, Isẹ Iransẹ naa lee jade sita. Se o rii? Ko awọn eniyan kan jọ, ẹ jọ gbọọ, ẹtẹti si daradara.

Awọn Ẹni Amin Ororo. Ẹ n gbọ ti awọn eniyan kan yoo wipe, "Ah! Bibeli wipe, ni opin ọjọ, awọn woli eke yoo wa, wọn yoo se awọn isẹ amin wọnyii". Iwe Mimọ niyẹn gẹlẹ. Nigba naa, nibo ni ipo ọrọ yii? A ni lati loo ni ọna ti o tọ. Lalẹ yii, mo fẹ sọrọ lori kókó yi, bi o bajẹ ifẹ Ọlọrun, Ọlọrun ti a fihan ninu Ọrọ Rẹ, bi o se jẹ pe a ko gbọdọ fi ojú si àyè etí, se o rii? O dabi, titẹ gbogbo Bibeli, gbogbo Bibeli si jẹ kiki Aworan Jesu Kristi. Nitori naa, mo fẹ sọrọ lori iyẹn lalẹ yii, bi Oluwa ba fẹ. Bi ko ba si ri bẹẹ, a o o waasu rẹ ni igba miran.

15 Bayii ninu Iwe Galatia. Ati ninu Iwe Kọrinti keji 4, ẹsẹ 1 titi de 6. Lẹhin naa, Galatia 1:1-4 mo fẹ ka Iwe Mimọ. Ninu Galatia 1:1-4,

> *Pọọlu, Aposteli* [Ẹ wo bi o se duro kia. Aposteli tumọ si "ẹnikan ti a ran, tabi akiri-waasu").
>
> *Pọọlu, Aposteli* (kii se lati ọdọ eniyan wa, tabi nipa eniyan, sugbọn nipa Jesu Kristi, ati Ọlọrun Baba, Ẹniti o ji I dide kuro ninu oku]
>
> *Ati gbogbo awọn arakunrin ti o wa pẹlu mi si awọn ijọ Galatia.*
>
> *Ore-ọfẹ si yin ati alaafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wa, ati Jesu Kristi Oluwa wa.*
>
> *Ẹniti O fi Oun tikalara Rẹ fun ẹsẹ wa, ki o lee gba wa kuro ninu aye buburu isinsiyi, gẹgẹbi Ifẹ Ọlọrun ati Baba wa. Ẹniti ogo wa fun, lae ati laelae, Amin.*

16 Bayii, ninu Iwe Kọrinti keji, ori kẹrin, a o o ka A lati ẹsẹ kin-in ni si ẹsẹ Ikẹfa.

> *Nitori naa, bi awa ti ni Isẹ-Iransẹ gẹgẹ bi a ti ri aanu gba, aarẹ ko mu wa.*
>
> *Sugbọn awa ti kọ gbogbo ohun ikọkọ ti o ni itiju silẹ, awa ko rin ni ẹtan, bẹẹ ni awa ko fi ọwọ ẹtan mu Ọrọ Ọlọrun sugbọn nipa fifi otitọ han, awa n fi ara wa le ẹri ọkan olukuluku eniyan lọwọ niwaju Ọlọrun.*
>
> *Sugbọn bi ihinrere wa ba farasin, o farasin fun awọn ti o sọnu:* [Bi eleyi ko ba fi iyantẹlẹ han, emi ko mọn ohun ti yoo mu jade.]
>
> *Ninu awọn ẹniti Ọlọrun aye yii ti sọ ọkan awọn ti ko gbagbọ di afọju. Ki imolẹ ihinrere Kristi ti*

*o logo, Ẹniti ise Aworan Ọlọrun, ki o mase mọlẹ ninu wọn.* (Bi o se ri ni Ọgba Edẹni: ẹ le wọn jade ki wọn ma baa fi ọwọ kan igi Iye).

*Nitori awa ko waasu awa tikarawa, bikose Kristi Jesu Oluwa, awa tikarawa si jẹ ẹru yin nitori Jesu.*

*Nitori Ọlọrun, Ẹniti o wipe ki imọlẹ ki o mọlẹ lati inu okunkun jade, Oun ni o ti mọlẹ ninu ọkan wa, lati fun wa ni imọlẹ imọn ogo Ọlọrun ni oju Jesu Kristi.*

17 [Aamin! Bayii ni ọrọ naa wi!]

Bayii, akori iwaasu mi lowurọ yi ni Ọlọrun Akoko Buburu yii. Bi a ti se ka ninu Ọrọ naa, ọlọrun aye yi, akoko buburu yii. Bayii, iwaasu yii n tọka si awọn ibi ti akoko buburu yii. O si jẹ igbagbọ mi pe gbogbo….. pe Bibeli ni idahun gbogbo fun akoko kọọkan, a si ti kọọ sinu Bibeli fun onigbagbọ akoko naa. Mo gbagbọ pe ohun gbogbo ti a nilo ni a ti kọ sinu Bibeli yii. O kan nilo ki Ẹmi Mimọ sipaya Rẹ fun wa. Emi ko gbagbọ pe, ẹnikẹni ni ayé yi ni ẹtọ lati se itumọ si Ọrọ Ọlọrun. Ọlọrun ko nilo ẹnikẹni lati tumọ Ọrọ Rẹ. Oun ni olutumọ Ara rẹ. O sọ wipe, ohun yoo see, O si n see.

Gẹgẹ bi mo ti sọ lọpọlọpọ igba. O wipe “wundia kan yoo loyun” O sọ eyii nipasẹ woli kan, o si se bẹẹ. Ẹnikan ko nilo lati sọ itumọ iyẹn. O sọ wipe ni ọjọ ikẹhin, “Oun yoo tu Ẹmi Rẹ jade sori gbogbo eniyan, ”O si se bẹẹ. Ko nilo ki ẹnikan tumọ rẹ. O wipe “ni igbẹyin ọjọ, awọn nkan wọnyii ti a ri to n sẹlẹ bayi yoo sẹlẹ. Ko nilo itumọ a ti tumọ rẹ. Se o rii?

18 Bayi, kiyesi gidigidi bi a se n kẹkọ Ọrọ naa. Ọlọrun Akoko Buburu yii, ti a n gbe inu rẹ yii. O lee sajeji, o sajeji pupọ, ninu akoko Ore-ọfẹ yii, nigbati “Ọlọrun n mu awọn eniyan kan, fun Orukọ Rẹ, Eyi ni Iyawo Rẹ, lati inu iran buburu ti a pe ni akoko buburu yii. Akoko gan an ti ”Ọlọrun n pe awọn eniyan kan fun Orukọ Rẹ, jade nipa ore-ọfẹ, a si pe e ni iran buburu. Bayi, a o o fi idi rẹ mulẹ pẹlu Bibeli, pe eyi ni akoko ti O n sọrọ nipa rẹ.

O sajeji pupọ lati ro eyi, pe ni iran ti o buru bi eleyii ni Ọlọrun yoo ma a pe Iyawo Rẹ. Kiyesi, o wipe awọn eniyan kan, kii se ijọ kan. Tori kin ni? Sibẹ, a pe e ni ijọ naa. Sugbọn Oun yoo pe awọn eniyan kan. Bayii, Ijọ jẹ akojọpọ awọn eniyan to jẹ onirun-u-ru. Sugbọn Ọlọrun n pe ọkan nihin. Ko sọ wi pe “Emi yoo pe Mẹtọdisti, Pẹntikọsiti” o wipe, Oun yoo pe awọn eniyan kan. Fun kin-ni? Fun Orukọ Rẹ. Se o rii, awọn eniyan kan. Ọkan lati Metọdisti, ọkan lati Baptisti, ọkan lati Ijọ Luther. Ọkan lati Katoliiki. Se o rii? Sugbọn O n pe awọn eniyan kan fun Orukọ Rẹ, ti o gba Orukọ Rẹ, ti a fẹ sọna ni Orukọ Rẹ ti wọn si n lọ si igbeyawo kan pẹlu Rẹ, lati di ara Ara Rẹ, nipa iyantẹlẹ. Gẹgẹ bi okunrin kan ti maa n yan iyawo ti o tọ kan laye, ti a yantẹlẹ lati jẹ ara rẹ. Gẹgẹ bẹẹ ni a se n yan iyawo Kristi bayii. Lati saaju ipilẹsẹ aye, Ọlọrun ti yan an tẹlẹ lati jẹ Ara naa. Ah!, Iwe Mimọ lọrọ pupọ, o kun fun oyin.

19 Kiyesi, kii se ohun ti ẹnikan ti sọ, ti ẹnikan ti pe, sugbọn ohun ti Ọlọrun yan saaju ipilẹsẹ aye, O si n pe awọn eniyan yii, ni ọjọ ikẹhin yii, kii se ẹgbẹ-to-fi-idari-eniyan-rọpo-idari-Ẹmi Mimọ. Awọn eniyan kan fun Orukọ Rẹ. Ni akoko buburu yii, ni Oun si n see, akoko ẹtan yii gan an.

Lọsẹ to lọ, ninu Matiu 24, ohun ni ìran to kún fun ẹ̀tàn julọ ninu gbogbo akoko. Gbogbo akoko ẹtan lati inu ọgba Edẹni lati ibẹrẹ dopin, ko tii si akoko kan to kun fun ẹtan bii ti akoko yii. Awọn woli eke yoo dide, wọn yoo si fi isẹ amin ati isẹ àrà han, to ba seese lati tan Ayanfẹ papa jẹ. Se o rii? Bayii, ijọ to tutu, to gan, to kun fun ẹkọ ẹsin lasan ko ni tilẹ mi Ayanfẹ, Ayanfẹ ko ni kọ bi-ara-si-iyẹn. Sugbọn, eyi to sunmọ otitọ pẹkipẹki yẹn. Fifi kiki Ọrọ Ọlọrun kan silẹ ni o nilo lati se. A seleri yi fun akoko yii, akoko to lagbara. Ẹyin Kristẹni ni ibi gbogbo, ẹ fiyesi wakati ti a n gbe inu rẹ yii! Ẹ sami si, ẹ kaa, ẹ fẹtisilẹ gidigidi.

20 Kinni idi ti Ọlọrun fi n pe awọn eniyan lati inu akoko buburu yi fun Orukọ Rẹ. Idi nipe, ki a le dan Obinrin yii wo, Iyawo Rẹ. Nigba ti o ba farahan faye ri, ti a fi da satani loju. Gẹgẹ bi o ti ri ni ibẹrẹ bẹẹ ni yoo ri ni igbẹhin.

Irugbin kan maa n bẹrẹ ninu ilẹ, yoo dagba nipasẹ awọn alaaru-iye, sugbọn ni opin rẹ yoo pada di eso ti o jẹ nigba ti a kọkọ gbin-in. Bi iru ẹtan se bẹrẹ ni Edẹni bẹ gẹlẹ ni yoo jẹ ni igbẹhin aye. Gẹgẹ bi Ihinrere se ri, nigbati o subu si ijọ-ẹlẹkọ-adamọ ni Nikia, Romu, yo pari si ẹgbẹ-to-feniyan-sadari-dipo-Ẹmi Mimọ to tayọ. Gẹgẹ bi Iru Ijọ tooto se subu nigba naa, pẹlu isẹ amin ati isẹ ara pẹlu Kristi ti o wa laaye laarin wọn, o n pari ni igbẹyin ọjọ yii labẹ Isẹ-Iriju-Iwaasu Malaki, ori kẹrin, o si dapada wa, Igbagbọ atetekọse ti wọn gba nigba akọkọ.

21 A rii bayi pe, iran buburu yi wá lati fi Iyawo Kristi han fun satani pe, Oun kii se bi Eefa, pe kii se iru Obinrin bẹẹ. A o o si dan-an-wo, nipa Ọrọ Ọlọrun. Iyawo naa, bi a se dan iyawo Adamu wo nipa Ọrọ naa, Iyawo Adamu si gba gbogbo ọrọ naa gbọ, sugbọn a da a loju ru, lori ileri kan, wi pe, “O jẹ ọkan naa, lana, loni ati titi lae” sugbọn o kuna lori ileri kan, labẹ idanwo ọta lojukoroju. Bayii, awọn eniyan ti a n pe mọn Orukọ Rẹ ni Iyawo Rẹ. Yoo wa sinu ohun kan naa ti o sẹlẹ tẹlẹ, kii se nipa otitọ ẹgbẹ-ẹlẹkọ-adamọ tabi ohun miiran

bikose Ọrọ Ọlọrun.

Nitori, ni ibẹrẹ Bibeli, a fun eniyan ni Ọrọ Ọlọrun lati maa gbe nipa Rẹ. Ọrọ kansoso ti a si tumọ nipasẹ satani ninu ẹranko-kan-to-pada-dejo. Ẹranko naa lee ba Eefa sọrọ, ó sì si Ọrọ naa tumọn fun Eefa, o si sọnu. Se o rii? O gbọdọ jẹ gbogbo Ọrọ naa.

22 Ni agbedemeji Bibeli, Jesu wa o si wipe "Eniyan ki yoo wa laaye nipa akara nikan, sugbọn gbogbo Ọrọ naa." Nigba ti satani dan an wo. Bayi, Ọlọrun n sọ fun wa ni opin ọjọ, pe "Ọlọrun aye buburu yii yoo dide ni igbẹhin aye". Ọlọrun saanu fun wa! Ẹ mase jẹ ka rìn pẹlu igberaga, to ti àyà sita, to mọ-ọn tan, nitori awa pẹlu wa ninu aigbọran nigba kan ri. Ẹ jẹ ki a wa si ibi Itẹ Ore-Ọfẹ, pẹlu ore ọfẹ, aanu ati imọlara ninu ọkan wa si Ọlọrun.

O ya ni lẹnu bayii, lẹhin iwaasu Ihinrere fun ẹgbẹrun ọdun meji o din ọgọrun ọdun, nisisiyi, awọn ìlànà aye buru pupọ ju igba ti Oluwa wa laye. Awọn ilana aye buru sii. Aye n lọ si asepari nla kan. Ẹ mọn eleyi. Oluwa n mu Ọrọ Rẹ sẹ ni gbogbo ọna.

23 Lana, mo duro…. Mo lero pe ẹni kekere naa…. Ko ni se bẹẹ, mo ti wá pẹlu Iyawo mi ati Mrs Wood, Arakunrin Roy Roberson, to wa nibi kan nihin, pẹlu Arakunrin Wood. A ti duro ni Ile itaja nla Youngtown Shopping Center, lati gba ohun kan ti Arabinrin Wood ni. Nigba ti a duro nibẹ, ọdọkunrin kan wa ba mi, o si darukọ rẹ fun mi. O si jẹ alejo si mi. Ọdọmọkunrin miiran tun wa, o wi pe, awọn wa lati Alabama, tabi mo gba pe Georgia nitoripe mo beere bi o ba mọn Arakunrin Welch Evans. A si sọrọ fun isẹju diẹ, Bi mo si ti fẹ maa lọ, ti ọdọkunrin yii wo oju mi, o si wipe, "ohun kan ni mo fẹ sọ".

Mo wi pe, "Se onigbagbọ ni ọ? Se Kristẹni ni ọ? O wi pe, "Rara".

24 Mo le má lee tun ọrọ rẹ sọ gẹlẹ bi o se sọ, sugbọn o jọ wipe, o ni iyemeji. Mo beere lọwọ rẹ nipa Angẹli Oluwa ti o farahan. Oun si wi pe, oun ti gbọ nipa Rẹ, sugbọn oun ko tii wa si ijọ yii ri. Mo wi pe, "Njẹ o gbagbọ bi"?

O dahun pe, Bẹẹ ni, Alagba. "o wipe", Mo ti n se akiyesi ohun kan. Awọn eniyan ti n sọ fun mi nipa awọn isọtẹlẹ wọnyii, emi si gbọ ninu ohùn Iwaasu rẹ ti a gba silẹ bi o ti sọ tẹlẹ pe Kalifonia yoo la danu bẹ yẹn. "o wi pe "Nigbati mo rii ninu iwe iroyin, nigba naa, mo gba a gbọ. Emi si nbọ loni tabi lọla fun igba akọkọ. "Eyii ni ni loni" fun igba akọkọ.

Mo wipe, "ki Oluwa bukun fun ọ, ọmọ, mo si bẹrẹ sii bọ lọwọ.

O wi pe, "sugbọn mo fẹ sọ ohun kan fun ọ alagba, mo sọnu bi eniyan se lee sọnu to. Mo dabi owo idẹ kan ninu iyanrin ọkọ kan, mo sọnu".

Mo wi pe, "sugbọn o ko nilati duro si ipo yẹn sibẹ. Ẹnikan wa nibi yii bayii ti o setan lati wa ọ ri ni kete ti iwọ ba setan".

O wi pe, "Mo setan"

Mo wi pe "se iwọ yoo tẹri rẹ ba?"

O wi pe, "oju ko timi"

Ki i se bẹẹ nikan, sugbọn o kunlẹ ni eekun rẹ mejeeji. Nibẹ, ninu páákì ọkọ yẹn, niseju gbogbo ero. Awọn ero oju popo n wo o. Nibẹ ni a gbadura pẹlu rẹ, titi ti o fi ọkan rẹ fun Ọlọrun. O wa sibẹ gẹgẹ bi ẹlẹsẹ, o si pada lọ gẹgẹ bi ọmọ Ọlọrun. O rin wa si ẹgbẹ ọkọ naa ni oku, o si pada ni alaaye.

Mo wi pe, "adagun omi fun itẹbọmi yoo si silẹ ni ọla".

Isun ka wa to kun fẹjẹ

T'o ti ha Jesu yọ

Ẹlẹsẹ mookun ninu rẹ

O bọ ninu ẹbi

Mo wi pe, dide ki a si tẹ ọ bọmi ni Orukọ Jesu Kristi, ki o maa kepe Orukọ Oluwa. Ọlọrun yoo kun ọ pẹlu Ẹmi Mimọ, yoo si fun ọ ni awọn ohun nla yii, yoo se ọ ni ẹni ti o lee ri i.

25 Kin ni? Aye ti n lọ si ipari. Tori kin ni? Ẹmi aibọwọ fun ofin, iwa ibajẹ, ẹsin nipa imọn ijinlẹ, ti mu ijọ de ipo "ile ẹyẹ aimọ gbogbo ati ẹyẹ irira" gẹgẹbi Bibeli ti wi. Ẹ jẹ ki a kaa Ifihan 18. Nigba ti a n bẹrẹ koko Ọrọ yii, ẹ si

Iwe Ifihan 18:1-5. Mo ro pe mo kọ eyi silẹ tọ́.

> *Lẹhin nkan wọnyi, mo si ri angẹli miiran, o n ti ọrun sọkalẹ wa ti oun ti agbara nla, ilẹ aye si ti ipa ogo rẹ mọlẹ.*
>
> *O si kigbe lohun rara wi pe, Babiloni nla subu, o subu, o si di ibujoko awọn ẹmi esu, ati iho ẹmi aimọ gbogbo ati ile ẹyẹ aimọ gbogbo ati ti ẹyẹ irira.*
>
> *Nitori nipa ọti-waini irunu agbere rẹ̀ ni gbogbo awọn orilẹ-ede subu, awọn ọba aye si ti baa se agbere ati awọn onisowo aye si di ọlọrọ nipa ọpọlọpọ wọbia rẹ̀.*
>
> *Mo si gbọ ohun miiran lati ọrun wa n wi pe, "Ẹ ti inu rẹ̀ jade ẹyin eniyan mi. ki ẹ ma baa se alabapin ninu ẹsẹ rẹ̀, ki ẹ ma baa si se gba ninu iyọnu rẹ̀.*
>
> *Nitori awọn ẹsẹ rẹ ga, ani de ọrun. Ọlọrun si ti ranti aisedeede rẹ̀.*

26 Iru ikilọ wo niyii! Eyi sọ ijọ pada si Ifihan 3:14, si igba Ijọ Laodikia gẹlẹ. Iwa aibikita fun ofin, o kun fun ẹsin, sugbọn ko bikita fun ofin Ọlọrun. "Nitori ti iwọ wipe awa lọrọ, a ko si salaini ohunkohun? Iwo ko si mọn pe, iwọ wa ni ihoho, o jẹ ẹni are, o fọju, o ko si mọn ọn". O ba Iwe Mimọ ti igba Ijọ yii mu, kii se fun Iwe Mimọ ọjọ ti Danieli, kii se ti ọjọ ti Noa, sugbọn ti iran buburu to gbẹyin yi.

Kiyesi nihin, "Iwọ wa ni ihoho". Jẹ ki iyẹn ki o wọ ọkan wa lọ daradara. Mo mọn pe, mo lee ni ọpọ atako lori ero yii, sugbọn o ti wa de ibi ti o fẹrẹ ma seese, ki Kristẹni jade ni ile rẹ, lai ba ara rẹ niwaju iran buburu yi nipa awọn obinrin ti ko wọsọ to bo ihoho ara.

27 Ẹyin obinrin, mo fẹ sọ eyi, mo si fẹ ki ẹ fẹtisilẹ, Ẹyin okunrin ati obinrin, ẹ lee tako eleyi, sugbọn a dari mi lati sọọ. Njẹ o mọn wi pe, obinrin ti o fi ihoho ara rẹ han bayi ko si ninu ọpọlọ pipe? Njẹ o mọn wi pe, asẹwo ni, yala o gba ohun ti mo sọ yii gbọ tabi ko gbagbọ, bi o ro bẹẹ tabi o ko ro bẹẹ? Bi Obinrin yi tilẹ lee duro niwaju Ọlọrun pẹlu ọwọ ti o na soke, ki o si bura wi pe okunrin miiran ko fọwọ kan ohun ri yatọ si ọkọ oun, ohun to sọ yi tilẹ lee jẹ otitọ, sibẹ asẹwo ni. Jesu wi pe, "ẹnikẹni ti o ba wo obinrin lati se ifẹkufẹ si ti baa se pansaga na", obinrin na si lee…………..

Woo, o wa ni ihoho. Bibeli wi pe "oun ko si mọn ọn", Ẹmi ti o n tami ororo lee, lati se ohun bi eleyi jẹ ẹmi ibi, ẹmi asẹwo. Ẹda rẹ ni ode ara, agọ ara rẹ, ẹran ara rẹ le mọn. O le ma se pansaga, o si lee bura si Ọlọrun ki o si jẹ otitọ, pe oun ko se pansaga rị, sugbọn ẹmi rẹ jẹ ẹmi asẹwo. Orisa iwọsọ ati imura ode oni ti fọ ọ loju tobẹẹ ti o fi n wọsọ ifẹkufẹ to si n jade sita bẹẹ.

28 Ni ijelo, Arakunrin Wood ati emi n ti ọkọ oju omi wa sinu odo. Mo ni lati kuro ni ile fun isẹju diẹ lati lọ si oju odo. Ibikibi ti a ba de, a ri awọn obinrin pẹlu asọ bikini" tabi ohun kan kekere lara wọn. Ohun to doju tini ni. Obinrin kan ko lee wa ni ori pipe, ki o wọ ohun yẹn sọrun. A kun un pẹlu ẹmi asẹwo. Arabinrin, ba Ọlọrun yanju iyẹn nitori iwọ yoo ri i ni ọjọ kan pe, otitọ ni.

Bawo ni iwọ obinrin, ti o si mọn bi ara rẹ ti lọwọ to, ti o wa tu ihoho rẹ sita niwaju awọn ẹmi esu onifẹkufẹ ẹlẹsẹ ti wọn n rin oju popo lọjọ oni? Bi awọn ọmọkunrin Ọlọrun ba si jẹ kiki ọmọkunrin Ọlọrun sibẹ, ti ọkọ rẹ si jẹ ọmọkunrin Ọlọrun, oun yoo mu ọ wọ asọ gidi tabi ki o fi ọ silẹ. Bi ọmọkunrin kan ba jẹ ọmọ Ọlọrun ko ni fẹ oun to jọ bẹẹ niyawo. Se o rii? O sọ wi pe, "Iwọ lo n sọ bẹ ẹ" Rara. Mo n sọ otitọ fun ọ, lọjọ kan iwọ yoo si pade rẹ. "O wa nihoho, pansaga ni, oun ko si mọn ọn".

Ah, Emi bura pe emi ko ti se lodi si ẹjẹ ọkọ mi ri". Ọkọ rẹ yoo da ọ lẹjọ fun un bi iwọ ba see, sugbọn Ọlọrun yoo da ọ lẹjọ fun iru ẹmi ti o wa ninu rẹ; Ọlọrun ko ni da ọ lẹjọ nipa ẹran ara rẹ, sugbọn nipa ẹmi rẹ, ẹni ti inu ni"

29 Eniyan ti ita ti a foju rí ní oòmọ̀n ara marun-un. Okunrin ti inu jẹ okunrin ẹmi ti o ni oomọn marun-un tii sẹ ẹri-ọkan, ifẹ ati bẹẹbẹẹ lọ. Ọkunrun ti ode ni, riri, titọwo, ifọwọkan, ìgbọ́-òórùn. Sugbọn ninu ẹmi yẹn ni ọkan kan wa, a si n dari rẹ̀ nipa ohun kan, tii se ifẹ-inu-rẹ, yiyan ohun too fẹ. Iwọ lee gba ohun ti esu sọ, tabi ki o gba ohun ti Ọlọrun sọ. Eyi yoo si fi ẹmi inu rẹ han. Bi o ba jẹ Ẹmi Ọlọrun, yoo maa jẹ ohun tii se ti Ọlọrun, ki yoo si jẹ ohunkohun tii se ti aye. Jesu wi pe, "Bi iwọ ba fẹ aye tabi ohun tii se ti aye, o jẹ nitori pe, ifẹ Ọlọrun ko i tii wọ inu ọkan rẹ rara". Satani ti tan ọ jẹ. "Eniyan ki yoo si wa laaye nipa akara nikan, bikose nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade". Kiyesii bayi, a sọ wi pe, o wa ni "ihoho" o kun fun ifẹkufẹ, o wa ni ihoho goloto.

30 O si da bi ẹni pe, aye wa ni iran to buru julọ ti o tii wa ri. Ko si iran kan ti awọn obinrin tii se bi wọn ti n se yii, ayafi iran ti o wa saaju ikun omi. Jesu si tọka sii. A o de ibẹ laipẹ.

Se Ọlọrun ti sọ agbara lati dari nu ni? Abi O kan n gba agbara miiran laaye lati dari aye? O se mi ni kayeefi. Idahun tootọ si ibeere yii gẹgẹ bi ero temi ni pe, awọn ẹmi meji ti wọn doju ija kọ ara wọn lo n sisẹ ninu aye loni. Ko lee ju awọn meji lọ, ori meji. Ọkan ninu wọn ni Ẹmi Mimọ to n sisẹ. Ekeji si ni ẹmi esu kan

ni opin aye yii ti o n sisẹ ẹtan. Emi yoo gbe ero mi le ori koko ọrọ yii fun iyoku iwaasu mi.

31 Awọn ẹmi meji naa. Ọkan ninu wọn ni Ẹmi Ọlọrun; ekeji si ni ẹmi esu, to n sisẹ ninu ẹtan. Awọn eniyan aye si nyan eyi ti o wu wọn bayii. Ẹmi Mimọ wa nibi, o n pe Iyawo kan jade fun Kristi. O n se e nipa jijẹri gbe Ọrọ Ileri Rẹ si Iyawo yii, fun iran yii, O n fi I han pe, Kristi ni. Bi o ba yẹ ki ika ọwọ se ohun kan ni iran yii, ika ọwọ yoo se. Bi o ba yẹ ki ẹsẹ tẹsiwaju, yoo see. Bi o ba yẹ ki oju riran ni iran yii, oju yoo riran. Se o rii? Ẹmi Ọlọrun, gẹgẹ bi o ti se dagba de ẹkun rẹrẹ iduro Ọlọrun, ohun ni iran ti a ngbe inu rẹ yii. Ẹmi Mimọ wa nibi, O n jẹri gbe Isẹ Iransẹ wakati yii. Ẹmi Mimọ si n se eyi, ki a lee pe awọn ti o gba Ọlọrun gbọ kuro ninu rudurudu yii. Ẹmi aimọ ti esu si wa laye, o n pe ijọ tirẹ jade nipa ẹkọ isina, bi o ti maa n se, nipa idibajẹ Ọrọ Ọlọrun, gẹgẹ bi o ti se ni ibẹẹrẹ. Ẹ rii ti o n padabọ si akoko irugbin lẹẹkan si lati Edẹni? Ohun tun ni yii lẹẹkan si.

32 Ni awọn iran ti o kọja, awọn eniyan jẹ ti ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Ẹ jẹ ti eyi, ẹ jẹ ti tọhun. Ki lo sẹẹlẹ si gbogbo ẹka ijọ-ẹlẹkọ-adamọ? O gbẹ danu. Ẹmi nfi ipele kọọkan silẹ, o si ntẹsiwaju, o si n pari sinu Irugbin kan. Se o rii?

Idanwo awọn mejeeji si mu wọn pada si atetekọse. Ma gbagbe eleyi bayi. Gẹgẹbi Johanu kinni 4: ẹsẹ ikarun ati ikẹfa ti o ba fẹ kọ silẹ, o pee ni “ẹmi isina” naa. Eefa ko kan jade sita, ko mọn-ọn-mọn wi pe, emi ko gba Ọlọrun gbọ. Rara. Isina kan ni o gbagbọ.

Satani ko kan jade wa sọ fun un pe “Rara, iyẹn kii tilẹ se Ọrọ Ọlọrun” o gba wi pe Ọrọ Ọlọrun ni, sugbọn o fi itumọ ti ara rẹ si. Ti Ọlọrun sọ fun wọn gbangba pe wọn ko gbọdọ se. Kin ni eleyi se? “O se isina to lagbara, fun awọn eniyan lati gba irọ gbọ, ki wọn si lee segbe nipa rẹ” Bi iwọ ba fẹ ka eleyi, Tẹssalonika keji 2:11 lo wa. Mo si ni awọn ẹsẹ Iwe Mimọ kan nihin, a ko ni lee ka gbogbo rẹ̀. A o maa darukọ ikọọkan rẹ fun yin.

Bi nkan yi ba sajeji si yin, ti ẹ ba ro wi pe, ki i se otitọ, a o o ka jade ninu Ọrọ Ọlọrun fun ibukun yin.

33 O se isina to lagbara gẹgẹ bi Iwe Mimọ ti wi. Tẹssalonika keji. Bayii, okunrin ẹsẹ yii yoo fi ara han, yoo si joko ninu Tẹmpili Ọlọrun, yoo maa fi ara rẹ han gẹgẹ bi Ọlọrun, yoo si mu ki awọn eniyan lọ sinu isina to lagbara lati gba irọ gbọ. Wọn yoo gba a gbọ, wọn yoo si segbe nipa rẹ̀. Ohun naa gẹlẹ ti o se si Eefa niyẹn. Ko sọ fun un pe, Ọrọ naa ki i se otitọ. Sugbọn o fun un ni isina to lagbara, eyi si mu ki o gba irọ gbọ.

Ẹmi isina jẹ ti esu. Awọn ẹmi esu n sisẹ bayi ninu awọn ọmọ alaigbọran. Aigbọran si kin-ni? Kin ni awọn ọmọ ọjọ oni n se aigbọran si? Gẹgẹ bi Eefa, ni atetekọse, wọn saigbọran si Ọrọ Ọlọrun tootọ. Ootọ ni yii. Bayii, bi o ba fẹ ka iyẹn….. Ẹ jẹ ki a sii. Efesu ori keji, ẹ duro na. Bi oju ko ba kan yin pupọ, o dara ki a ka diẹ. Efesu 2:1-2.

Ẹyin ni O si ti sọ di aaye, nigba ti ẹyin ti ku nitori irekoja ati ẹsẹ yin.

Ninu eyiti ẹyin ti n rin ri gẹgẹ bi ipa ti aye yii, gẹgẹ bi alasẹ agbara oju ọrun, ẹmi ti n sisẹ nisinsinyi ninu awọn ọmọ alaigbọran.

34 [Awọn Ọmọ alaigbọran]

Bi ẹmi asodisi-Kristi ni atetekọse gẹgẹ bi ọmọ-ọwọ, ba sisẹ nipa aigbọran, nigba naa, kin ni yoo jẹ nigba ti o ba pari ninu ẹni tii se asodi-si-Kristi? Bawo ni yoo se lee tan ni jẹ to! Melomelo ni bi agbara itanijẹ agbalagba yoo se ju ti ọmọde lọ, ti yoo fun araye? O si wipe, “Ẹmi isina ti o n sisẹ bayi ninu awọn ọmọ alaigbọran” to n saigboran si Ọrọ naa.

Kiyesi. Mo fẹ sọrọ lori eleyi fun isẹju kan,"awọn ọmọ alaigbọran,"ọmọ kan. Njẹ o mọn pe ni ibẹrẹ rẹ, mo lee fi da ẹnikẹni loju nipa Ọrọ Ọlọrun pe, iwọ wa ninu baba nla rẹ. Ati baba baba nla rẹ. O sọkalẹ wa sinu baba baba rẹ, lẹhin na, sinu baba rẹ, lẹhin na iwọ gan an. Se o mọn eyii? Bibeli wi pe, mo gbagbọ pe Heberu 7, Melkisedeki nigba ti Abrahamu n pada bọ lati ibi ti o ti pa awọn ọba “Abrahamu san idawẹwa gbogbo ikogun fun Melkisedeki. A si ri Pọọlu nihinyi ti o sọ pe, ”Leefi ti o ngba idawẹwa, ti san idawẹwa fun Melkisedeki nitori o si wa ninu Abrahamu nigba ti o pade Melkisedeki. Ohunkohun ti Abrahamu se, a ri pe, Lefi si wa ninu Abrahamu ti i se baba, baba nla rẹ. Abrahamu bi Isaki, Isaki bi Jakobu, Jakobu bi Lefi ati awọn baba nla to ku. Nisisiyi, a ri iyantẹlẹ kedere bayii.

35 Bayi, ninu awọn iwaasu yii, mo fẹ tẹnumọ awọn nkan ti mo ti sọ fun yin ninu Isẹ-Iransẹ ti Imọlẹ asaalẹ yii, ti Ọlọrun sọ pe yoo wa sori ilẹ aye.

Ẹ kiyesi, “Ẹranko naa ti yoo wa sori ilẹ aye yoo tan gbogbo awọn ti a ko kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye ti Ọdọ-Aguntan, ti a ti pa saaju Ipilẹsẹ aye”.

Ninu ero ti Oluwa, Ọlọrun Ẹmi nla Ni. Ni atetekọsẹ, ki ipilẹ aye to wa, o jẹ Ọlọrun. Njẹ iwọ si mọn pe, o wa ninu Rẹ̀ nigba naa? Nigba naa, bi o ba ri bẹẹ, gbogbo Ẹni-ti-Ọlọrun-Ise ni o farahan ninu Jesu Kristi.

Nigba ti Jesu Kristi si ku lori agbelebu, mo ku pẹlu Rẹ, nitori mo wa ninu Rẹ nigba naa; nitori Oun ni ẹkunrẹrẹ Ọrọ naa, to farahan-faye-ri, o mọn wi pe, awa yoo farahan-faye-ri lati igba naa lọ. A si wa ni kalfari pẹlu Rẹ. A lọ sinu iboji pẹlu Rẹ, a si jinde pẹlu Rẹ. Bayii, awa ti goke nipa Ẹmi Rẹ lọ si Itẹ ore-ọfẹ, a n joko papọ ninu awọn Ọrun ninu Jesu Kristi ni gbogbo igba.

36 Nitori bi iru iye ti eniyan se sọkalẹ wa tabi iru kan ninu baba-nla de inu baba, titi o fi farahan gẹgẹ bi eniyan, gẹgẹ bẹẹ ni Iye Kristi se sọkalẹ wa lati gbe ara wọ ninu wa. Idi niyi, ti Oluwa fi lo Ẹmi Elija nigba marun-un ọtọọtọ. Kin ni? O jẹ ifarahan isọkalẹ rẹ.

Gẹgẹ bi iye rẹ bi eniyan ati awọn iwa idamọ rẹ se sọkalẹ nipasẹ ibimọ lati ọdọ awọn baba rẹ, bẹẹ gẹgẹ ni Ẹmi Ọlọrun ti a yan tẹlẹ saaju ipilẹsẹ aye. Nigba ti ẹkunrẹrẹ Ọrọ Ọlọrun si farahan ninu Ara eniyan kan, ti a pe ni Jesu Kristi, nibẹ, Ọlọrun mu mi san gbese ẹsẹ mi ninu rẹ. Lẹyin naa, o ji mi dide pẹlu Rẹ ninu ajinde Rẹ. Bayii, a si joko pẹlu Rẹ pẹlu agbara ati asẹ lori gbogbo ẹmi esu. Ah! Bi Iwọ ba lee gba ohun ti Ọlọrun ti fun wa gbọ! Sugbọn bi Iwọ ko ba joko nibẹ, iwọ ko nii" Bi Iwọ ba si joko nibẹ, ti iwọ ko si gba a gbọ, ti ẹru nba ọ lati tẹ siwaju, Iwọ ko ni i lo lae. Sugbọn bi iwọ ba joko nibẹ, iwọ yoo lo; nitori a ti yan ọ tẹlẹ lati se ohun ti iwọ ba se.

Ni idakeji lọhun, a gbe Farao dide fun idi yii, Bibeli sọ wi pe, ki o lee jẹ Farao. A gbe Judas Iskariotu dide lati jẹ ọmọ egbe.

Kiyesi bayii, Otitọ nla ti a n sunmọ yii.

37 A rii wi pe, Ijọ kọ Ọrọ Ọlọrun lati jọba lori wọn, wọn si gba Barabasi dipo. Ti o ba fẹ mọn ibi ti o wa ninu Bibeli, ohun ni Mathew 27:15-23. Kin ni eyi se? Ipo wo ni eyi se? Ronu nipa rẹ. Nigba ti ijọ agbaye ninu ifi-idari-eniyan-rọpo Ẹmi Mimọ, ti awọn okunrin mimọ olododo, bi wọn se ro pe wọn jẹ, ati bi wọn se ri loju awọn eniyan. Wọn kan Jesu mọn agbelebu, wọn si wi pe, “awa ko lee gba okunrin yi laaye lati jọba lori wa. Johanu kin-in-ni, ori kin-in-ni salaye rẹ. Wọn si wipe,”awa ko ni gba Ọrọ Ọlọrun yi laaye lati jọba lori wa“. Sibẹ Oun ni Ọrọ naa, sugbọn a fọ wọn loju si Oun ti O jẹ. Nitori pe Oun ni imusẹ gbogbo awọn isọtẹlẹ to yẹ ko wa si imusẹ. Bayii, gbogbo wa le gba eyi gbọ, nitori awa n wo ẹyin lati ri ohun to ti sẹlẹ. Sugbọn bi aye to wa nisisiyi, aye iran buburu yii, bi wọn ba wa laye nigba naa lọhun, wọn yoo se ohun kan na gẹlẹ ti wọn nse loni, tori pe Ọrọ kan naa sì ni sibẹ, pẹlu iran yii ti o n farahan. Awọn yoo see. Wọn ko lee se ohun miiran. Wọn jẹ awọn ọmọ alaigbọran, ti a ti fun ni isina to lagbara, lati gba irọ́ gbọ, ki wọn si segbe nipa rẹ.

38 Kiyesi i, nigba ti ijọ aye ko gba Jesu tii se Ọrọ Naa ti o farahan faye-rii ni ọjọ naa. Nitori kin ni? Wọn ti tumọ rẹ ni ọna miiran. Sugbọn o yẹ ki wọn ti mọn pe Oun ni Ọrọ naa. Nitori pe O se ohun gbogbo ti Ọlọrun sọ pe Oun yoo se. O si wi fun wọn pe, “Ẹ wa ninu Iwe Mimọ, fun akoko yii, bi Emi ko ba si ba akayẹ ohun ti a sọ pe, Emi yoo se” ẹ ma gba Mi gbọ.

Wọn wi pe, “Awa gba Mose gbọ”.

O wipe, “Iba jẹ wi pe, ẹyin gba Mose gbọ ni, ẹyin iba gba Mi gbọ nitoripe Mose sọrọ nipa Mi”. Sibẹ, wọn ko rii. Ọlọrun Ọrun gan an ti O n ku lori agbelebu, ti O si n sọ awọn Ọrọ ti wolii sọ pe yoo sọ, sibẹ ko ye wọn. Se o rii? Wọn kii se iru bii tirẹ. Wọn kii se Ọrọ naa. Sibẹ, wọn jẹ ẹlẹsin pupọ. Sugbọn wọn kii se Ọrọ naa, nitori pe oun i ba ti mọn ipo rẹ fun akoko naa.

39 Kiyesii bi o ti dara to, bi Iwe Mimọ se n so mọ ara wọn fun iran kọọkan. Kiyesi bayii, nigba ti Ijọ aye ko si gba Ọrọ Ọlọrun laaye lati se alakoso lori wọn, wọn gba Barabasi, ti i se apaniyan. Kin ni eyi se? O gbe satani ga soke, ọlọrun iran buburu yii si ipo ti o ti n fẹ lati ibẹrẹ.

Fetisilẹ bayii, Nitori a ko sọ pe satani jẹ ọlọrun iran miiran bikose iran yii. A ko sọ pe o jẹ ọlọrun ni iran Noa, A ko sọ pe o jẹ ọlọrun iran Mose, tabị olọrun igba ijọ Elijah. Sugbọn iran buburu yii. Oun ni. Ah. Ma se alai-ri eleyi. Oun ni ọlọrun iran buburu yii ti ọkẹ aimoye eniyan n bọ, wọn ko si mọn ọn.

Sugbọn ẹ jẹ ki Iwe Mimọ si asọ lori rẹ ni owurọ yii, nigba naa, iwọ yoo mọn ọn. Gẹgẹbi o ti se ma n ri ni ipade imọn-nipa-Ẹmi, nigba ti Ẹmi Mimọ, ba bọ si inu Ọrọ Rẹ ti O ba si pe okunrin kan jade ti O wi pe, "Ko tọ fun ọ lati maa ba obinrin yẹn se pansaga. Tori kin ni o se se iyẹn ni ọdun mẹwa sẹyin, nigba ti o lọ se ifẹkufẹ pẹlu iyawo okunrin yẹn?" Kin ni o n se? O n tu u lasiri, o n tu asiri satani, ti o ti gbe okunrin yi de, tabi obinrin to n gbe pẹlu ọkọ obinrin miiran, tabi awọn ẹsẹ ti wọn ti da, ohun ti wọn ti se. Kin ni o n se yi? O n tu asiri rẹ.

40 Awọn onisegun mu irin isẹ wọn lati wa ohun ti o kuna. Wọn ko lee see. A ko lee sọ. Sugbọn Ẹmi Mimọ yoo wa fi oun ti o jẹ han. Yoo tu asiri rẹ̀. Se o rii. Oun ti Ọrọ Ọlọrun jẹ niyii. O jẹ Imọlẹ ti O n tan si okunkun. Nigba ti iwọ ba si gbọ ariwo kan ninu iyara. Ariwo ti o sajeji. O ko mọn ohun ti o jẹ, awọn nkan kan sa n se ohun kan. Tan imọlẹ si i. Kiakia, awọn irẹ ati aayan, awọn ọmọ okunkun. Bi imọlẹ ba si de, wọn yoo fọnka kia. “Wọn jade lọ kuro lọdọ wa nitori wọn kii se ara wa" ni Bibeli wi. Wọn ko lee gbe ninu Imọlẹ aye. Nitori Ọlọrun Ọrun ti ran Imọrẹ Rẹ ni opin ọjọ yii ki O lee tan Imọlẹ si ọna awọn ọmọ Rẹ, ki wọn ma baa rin ninu

okunkun ki wọn si subu, sugbọn ki wọn baa rin ninu imọlẹ Itansan Jesu Kristi, ọkan naa lana, loni ati titi lae. Amin.

41 Kiyesii, a ko pe satani ni ọlọrun iran miiran bikose ọlọrun iran yii. O ti jẹ ilakaka rẹ, lati dabi Ọlọrun lati ibẹrẹ pẹpẹ wa. Jẹ ki a ka eleyi. A o o kan gba akoko wa. Jẹ ki a pada lọ si Isaya 14 ki a si ri ohun ti Ọlọrun sọ pẹ olọrun aye yi…… ohun ti satani se. Isaya 14:12, kiyesi.

Bawo ni iwọ ti se subu lati ọrun wa, iwọ Lusiferi, irawọ owurọ! Bawo ni a ti se ke ọ lulẹ iwọ ti o sẹ́ awọn orilẹ ede ni apa!

Nitori iwọ ti wi ni ọkan rẹ pe, emi yoo goke lọ si ọrun, emi yoo gbe itẹ mi ga kọja awọn irawọ Ọlọrun [awọn ọmọ Ọlọrun bayii], emi yoo si joko lori oke ijọ eniyan, ni iha ariwa.

O jẹ ilakaka satani pe ki wọn maa sin-in bi ti Ọlọrun. O gba idameji ninu idamẹta awọn angẹli Ọrun. O gbe ara rẹ soke ju awọn irawọ o si waasu fun wọn, o si tan idameji ninu idamẹta awọn irawọ naa. Se o rii? O dara. Kiyesii, ilepa rẹ niyẹn. Bayii, o si ti setan pẹlu iyawo rẹ ti o ti fi arabalẹ̀ yan, ti o si ti kọ ni imọn tirẹ, se o rii. Ti gbogbo wọn si ti fi ọda kun oju nipa ẹtan rẹ, nipa ile ijọsin nla, nla ti ijọ-ẹlẹkọ-adamọ, ati ẹsọ ara ti imọn ati ẹkọ ẹsin rẹ, nipa pe, o jafafa, o jẹ ọmọwe to tayọ, ti o si kẹkọ lati tan gbogbo aye jẹ, ki o si di ọlọrun kan. (Ohun ti o si ti se niyi). Gbogbo rẹ, n parapọ lọ si ẹni-asodisi Kristi, ti a ti de lade “ni ipo Ọlọrun” tabi “asoju Ọlọrun”, lati ọwọ iyawo rẹ onifẹ-aye, onimọ-ijinlẹ, ti a wọ lasọ nla ti imọ-iwe ati ẹkọ ẹsin. Iyawo yii kun fun ẹsin bii tirẹ ati nipa itumọ Ọrọ Ọlọrun fun un gẹgẹbi o ti se fun Eefa ati bi Kaini ọmọ rẹ̀ se se.

Bayi o sọ pe“ọmọ satani” ni Kaini?

42 Fi ibi kan han mi ninu Bibeli ti a ti pe Kaini ni ọmọ Adamu. Bibeli wi pe, o jẹ "ọmọ ẹni buburu ni" iru ẹranko-to-pada-dejo. Rara, a ti si iboju naa kuro bayii, arakunrin. A ti si ile alaramọnda naa, gẹgẹbi isipaya se fihan.

Kiyesi oun ti yoo se, awọn ero re. O ro pe Ọlọrun n gbe ninu ẹwa ti aye. O se eyii ni ọrun. Ẹsẹ ko bẹrẹ ninu ọgba Edẹni. O bẹrẹ ni Ọrun nigba ti Lusiferi irawọ owurọ gbe ara rẹ ga ni ẹwa, ti o si safẹri ijọba ti o lẹwa ju ti Maikẹli. O si ro pe, Ọlọrun n gbe ninu ẹwa.

Si kiyesi Kaini. Oun ko fẹ irubọ ti o ni ẹjẹ. O wa rubọ pẹlu eso, tabi awọn nkan ẹlẹwa lori pẹpẹ. O kun fun ẹsin, o se ohun gbogbo gẹgẹbi Abẹli ti se. O rubọ, o wolẹ niwaju Ọlọrun ni ijọsin, o se igbọran ni ọna gbogbo sugbọn lai ni ifihan Ọrọ naa. Ọrọ naa si jẹ eto Ọlọrun lati atetekọse. Sugbọn Ọlọrun fihan nipa isipaya, ohun gan an ti o jẹri gbe ti o si fi amin si gẹgẹbi otitọ. Kii se ẹsin, kii se pẹpẹ, kii se jijẹ ọmọ ijọ, kii se sise irubọ, kii se, jijẹ olootọ, sugbọn nipa isipaya Ọrọ Ọlọrun. Ti Ọlọrun sipaya fun un, ohun ti o jẹ gan an. Iya rẹ ko jẹ apulu kan ti ejo kan fun un, sugbọn o ni Ibalopọ pẹlu satani nipasẹ ẹranko naa. Kii se ẹda afayafa, sugbọn ẹranko ti o jafafa julọ, ti o ni arekereke julọ ninu gbogbo ẹranko igbẹ. O wa ni aworan eniyan, ẹda kan soso ti iru rẹ lee dapọ mọn ti eniyan. Bayi imọ ijinlẹ n gbiyanju lati rii. Wọn ko si lee rii, nitori pe a ti yi gbogbo egungun rẹ pada. Sugbọn, Bibeli sọ pe bẹẹ ni o ri

43 Kiyesi ohun ti ẹda yi yoo se. Okunrin yii, “oun yoo joko ninu Tẹmpili Ọlọrun, ”eyi ni ijọ, “yoo maa fi ara rẹ han gẹgẹbi Ọlọrun”. Bi o ba fẹ ka eleyi, o wa ni Tẹsalonika keji 2:3-4, ati Ifihan 13:4,11,12, nibiti awọn wolii mejeeji, Pọọlu ati Johanu ti sọrọ nipa ohun ti ẹranko naa yoo jẹ ni opin ọjọ yii. Ki ẹ kaa, nitori mo kọ silẹ, sugbọn mo fẹ pa akoko mọn

Iwe Mimọ pe akoko ti a n gbe inu rẹ yii ni “ọjọ ti eniyan”. Eyi kii se ọjọ Ọlọrun. Ọlọrun kii se ọlọrun aye yii. Bibeli wi pe Oun kọ ni. Ọlọrun ọrun ni. Sugbọn eyi kii se ọjọ ti Ọlọrun. Ọjọ yiyan ohun ti o fẹ ni a wa yii. Yala ki o gbe igbe aye rẹ fun ọjọ oni ki o si ku. Yan Ọlọrun ki o si ye. Ọlọrun si ni Ọrọ Naa, Ọrọ na si ni Ọrọ ri o farahan-faye-ri fun wakati ati ọjọ naa.

44 Kiyesi ọjọ ti eniyan. Bi o ba fẹ kọ eyi silẹ, mo fẹ kaa tẹlẹ. Sugbọn Korinti kin-in-ni 4:1-5 n sọrọ nipa Pọọlu, pe eniyan n da oun lẹjọ ni ọjọ ti eniyan.

Ọjọ oni…. “Kin ni o pe e ni ọjọ eniyan fun?” O jẹ ọjọ ti a n se awọn isẹ ọwọ eniyan nipa imọn eniyan logo. Ẹ wo gbogbo ifọnnu awọn ijọba, aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ, ẹnikan n gbiyanju lati mu ẹnikan de oju osupa. Ọlọrun n gbiyanju lati mu ẹnikan de Ọrun. Se o rii? Sugbọn ẹ wo bi wọn ti n na ẹgbẹlẹgbẹ owo dọla lori ohun ti ko nidi. Nigba ti wọn ba de oju osupa, ko si ohun ti wọn yoo ri. Kin ni o se wọn gan? Emi ko bikita nipa osupa. Mo fẹ yara kọja osupa kiakia to bẹẹ ti emi ko tilẹ ni rii. Ki n saa maa lọ soke sii. Mo fẹ kọja awọn irawọ [alakojọpọ miliki waiti wee], ki n saa maa lọ. Bẹẹ ni.

45 Aye loni si n yara wọn sọtọ fun imọn to wa nipa satani. Wọn si se ọjọ eniyan logo kii sii se nipa Ọrọ Ọlọrun, sugbọn nipa imọn ti o ni. Bayi, ròówò. Jẹ ki ọrọ yi wọ ọkan rẹ. Nigba ti o ba si n gbọ ohùn ti a gba silẹ yii, duro diẹ ki o si ròó wò.

Wọn gbe isẹ rẹ ga ju Ọrọ Ọlọrun lọ. Awọn ifarahan isẹ rẹ tii se ọgbọn satani, eyi ti o fifun Eefa ni atetekọse. Fetisilẹ bayii, mase padanu eleyi. Wọn gbe ọgbọn satani ga soke si ori itẹ ijọsin ninu eniyan loni ju Ọrọ Ọlọrun ọjọ oni ti Ọlọrun fẹsẹ Rẹ mulẹ. Awọn ijọ wa fẹsẹ eleyi mulẹ nipa awọn ile ẹkọ ẹsin wọn, awọn ile iwe wọn, ti o n kọ wọn ni awọn nkan ti Ọrọ Ọlọrun ko mọn gẹgẹbi awọn ti lero. Nibẹ, ọmọwe lagbaja; olukọni lakasegbe, ọjọgbọn lamurin ati bẹẹbẹẹ lọ ti gbe imọn wọn soke, ti wọn pe ni otitọ, [sugbọn ọdọ satani ni o ti wa], ga ju Ọrọ Ileri, ti Ọlọrun jẹri gbe, ti O si sọ di kedere niwaju wọn. Awọn eniyan si subu fun un. Se o rii?

Awọn aseyọri iwadi imọn-ijinlẹ rẹ ti o n gbiyanju lati fi daniloju pe Ọrọ Ọlọrun kuna. Saa ro eleyi. Wọn fi ẹkọ ẹsin ti eniyan salaye Ọrọ Ọlọrun fun awọn eniyan, wọn si sọọ di alailagbara, bi o se ri ni iran to fi-ẹkọ-eniyan-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun nigba ti Jesu farahan laye. Jesu wi pe, “Ẹyin alagaba-gebe! Ẹyin, nipa asa yin” [eyi ni itumọn wọn] “ẹ ti mu Ọrọ Ọlọrun, ẹ si ti sọ ọ di alai-lagbara si awọn eniyan”. Ohun kan naa gẹlẹ ni wọn si ti se loni. Ko nipa to yẹ.

46 Kiyesii. Awọn eniyan ti gbee ga ju ohun gbogbo ti a n pe ni Ọlọrun. Njẹ Tessalonika keji ko sọ pe wọn yoo se bẹẹ? Si wo o, asẹ ti ijọ ẹlẹkọ-adamọn kan ni. Awọn eniyan gba ijọ ẹlẹkọ-adamọn naa gbọ ju Ọlọrun lọ. Ọlọrun si ni Ọrọ naa. Wọn yoo gba ẹkọ-adamọ ijọ wọn gbọ dipo Ọrọ naa, eyi si gbe e [asodi-si-Kristi] ga ju gbogbo ohun ti a n pe ni Ọlọrun. Ọlọrun kan soso lo wa, eyi si ni Ọrọ naa. “Gbogbo ohun ti a n pe ni Ọlọrun; nitori naa, oun gẹgẹbi Ọlọrun, joko ninu ijọ Ọlọrun, o si n fi daniloju pe oun ni Ọlọrun” nitori pe o ti mu ki awọn eniyan naa maa sin oun. Ọlọrun ni Ọrọ naa. Oun si gbe ara rẹ ga ju gbogbo ohun ti n jẹ Ọlọrun. Ọlọrun kan soso ni o si wa, Ọlọrun yii si ni Ọrọ naa. Se o rii? Gbogbo ohun ti a n pe ni Ọlọrun“ jasi pe ọlọrun iran buburu yii ti gbe ara rẹ ga ju Ọrọ Ọlọrun tootọ ti a jẹri gbe lọ. Ihinrere ti Johanu 1 ni yii. Se o rii? ”Ju gbogbo ohun ti a n pe ni Ọlọrun, to bẹẹ ti o joko bi Ọlọrun ninu tempili Ọlọrun“, pẹlu asẹ. Woo, wọn si n yin-in fun eyi! A! Ọlọrun, jẹ ki awọn eniyan ri ẹtan yii! Wọn n yin-in fun, awọn eniyan iran buburu yii si gba a gbọ tọkantọkan. Bayii, njẹ iwọ ri ọlọrun iran buburu yii ati awọn iransẹ rẹ?

47 Bayii, ẹ jẹ ki a wo o, bi o se n farahan gbangba. O sọ pe, oun n se aye to dara si fun wọn lati gbe inu rẹ, nipa imọn rẹ to yatọ si Ọrọ Ọlorun ti ko kuna rii. Sugbọn nipa ikojọpọ pẹlu ijọ-ẹlẹkọ-adamọ rẹ, ati ẹkọ adamọ rẹ, ati ọgbọn iwe rẹ, ati imọ-ijinlẹ rẹ, ati bẹẹbẹẹ lọ, oun n da aye to dara si fun eniyan lati maa gbe; o si n pa Ileri Ọlọrun tii, ti o sọ pe “akoko Ijọba Ẹgbẹrun ọdun nikan ni aye yii yoo dara fun eniyan lati gbe inu rẹ. Ni ero temi, o ti mu aye yẹ lati dẹsẹ ninu rẹ ju ti tẹlẹ lọ.

Kiyesi, Njẹ o see bi? O mu ẹsẹ ba ofin mu. O gba mimu ọtin wisiki laaye ati mimu siga. Ati ninu awọn ijọ, o sọọ di ohun to ba ofin mu pe ki obinrin ge irun rẹ ki o si jẹ ọmọ ijọ sibẹ. Bayi duro die na.

48 O lee wọ asọ penpe, ki o kun oju, ki o si jẹ ọmọ ijọ sibẹ, ti eyi si lodi patapata si Ọrọ Ọlọrun. O sọ fun un pe, ohun ti o se yi dara. Se o ri imọn rẹ? “kin ni iyẹn nii se pẹlu obinrin? ”Gẹgẹ bi o se ri pẹlu jijẹ eso ti a pasẹ fun wọn pe ki wọn ma jẹ. Yala o tọ, tabi ko tọ, ohun ti o jẹ naa ni yii. Ọlọrun so pe ki o ma see. Sugbọn o n see.

Ijọ eniyan si gba a gbọ, o si ni fẹ rẹ. O korira Ọlọrun. Awọn isẹ rẹ fihan bẹẹ. O fenu jẹwọ pe oun nifẹ Ọlọrun, sugbọn o nifẹ satani. O n sin ọlọrun 'imura-ode-oni', Ọlọrun aye yii, Awọn orisa-obinrin ti ilu-ibajẹ Holliwuudu. O nifẹ ẹ rẹ, sugbọn o korira Ọrọ Ọlọrun tootọ, tii se Ọlọrun tootọ kan soso ti o wa. Wọn sọ awọn nkan wọnyi di ohun to bofin mu ninu awọn ijọ. “ko si ohun to buru nibẹ, ”awọn obinrin wa lee se eleyi, ati tọhun“ Sugbọn niwaju Ọlọrun alaaye, a ko tilẹ gba a laaye lati wa, aya fi bi o ba wa pẹlu ironupiwada.

Se o rii, oun ni ọlọrun ẹwa aye, oun ni. Awọn ijọ fẹ rẹwa. Oun [Ọlọrun iran buburu] yi si ni ọlọrun ẹwa lati atetekọse. O lee se, o si ti sase-yọri nipa imọn rẹ ninu imọ ijinlẹ ati awọn isẹ ọwọ rẹ, lati se ohun ọsọ ati ẹwa fun iran ibi yi. O ti se ẹwa.

49 Kiyesi O se Pataki lati fiyesi. Ni atetekọse, Sẹẹti ati awọn ọmo rẹ ko lọ ni Ọna imọ ijinle. Bayi, a oo sọrọ nipa imọn Ijinlẹ fun isẹju diẹ. Bi mo ba sọ eleyi, kii se lati se awawi fun aimọnkan mi, Sugbọn, awọn ẹgbẹ alaimọkan ni ohunkohun ti yoo sẹ Ọrọ Ọlọrun. Se o rii? Bẹẹ ni oyẹ fun afiyesi kiyesi. Awọn Ọmọ Sẹẹti ko lọ si ipa imọn ijinlẹ. Sugbọn wọn jẹ darandaran onirẹlẹ, agbẹ abb. Sugbọn awọn ọmọ Kainin se bẹẹ. Toni kin-ni? Wọn ni imisi lati ọdọ baba wọn esu. Kaini ni imisi lati ọdọ baba re, esu, awọn iran eyii si gba imisi lati iru naa to n tesiwaju lati iran de iran.

Kiyesi iru ti Ọlọrun bi o ti n sọkalẹ bọ lati iran de iran, si kiyesi ibi ti o n pari si loni. Kristẹni, awọn ojulowo kristẹni ko gbe igbagbọ wọn lori imọn ijinlẹ ati awọn nkan bẹẹ. Rara. Duro na, a oo de inu eleyi laipẹ. Sugbọn Kaini sisẹ nipa imọn ijinlẹ ni ibamu pẹlu iwa ẹda baba wọn, esu ti o kun fun imọn aye, ẹwa, imọn ijinlẹ, ati bẹẹbẹẹ lọ. Awọn ọmọ Kaini se awari nipa imọn ijinlẹ. Wọn jẹ ọmọwe. Wọn lo ohun elo orin, wọn dabi Elvis Presley ọjọ oni, bi awọn nkan wọnyii ti awọn igbimọ ile iwe maa ngba laaye ni adugbo ni alaalẹ Satide. Wọn kọ́ Ilu nla-nla, wọn n se awọn obinrin lọsọ fun ifẹkufẹ ara wọn, gẹgẹ bi esu se nfun wọn ni ọda ikunra, ti o n ge irun wọn, ti o si nfi wọn sinu asọ penpe ati bẹẹbẹẹ lọ. O si wa fun ifẹkufẹ rẹ ti o dọtin. Eyi ko dun leti sugbọn, emi ko mọn ọna miiran lati sọọ.

50 Bayii, a mọn pe, ihinrere esu jẹ ihinrere imọn ijinlẹ ati ilọsiwaju. O waasu rẹ ni Edẹni. Ọlọrun kọ lo wasu rẹ, satani ni. Imọn ijinlẹ ti ilọsiwaju. Imọn ijinlẹ ati Ilosiwaju jẹ ihinrere ti Satani. Wo ibi ti o si mu wa de loni pẹlu rẹ. Se o rii.

Kiyesi, O waasu rẹ ni Edẹni si tani? Si iyawo Adamu. Oun si subu fun. O tan an jẹ lati se iyemeji si ọkan ninu Ọrọ Ọlọrun. Jẹ ki a wo ohun ti o nilati sọ fun. O nilati sọ fun pe, “ko tilẹ ba imọn-ijinlẹ mu lati ku, ninu ijọ mimọ yii” Tabi “A o o kọ ọ ni imọn ati ẹkọ, ki iwọ maa baa gba awọn ohun ti ko mọgbọn dani bi iku gbọ. Emi ko fẹ mọn bi Ọrọ Ọlọrun sọ ọ tabi ko sọ, sugbọn ko ba ọgbọn mu.”

51 Ah! Wo o loni. “Ọlọrun rere ni Ọlọrun. Iwọ si wa ninu Ijọ Mimọ Rẹ, họwu! iwọ ko lee ku”. Sugbọn Ọlọrun sọ wi pe, iwọ yoo ku, o si tan sibẹ. Se o rii loni? “Ah, saa ti jẹ ọmọ ijọ, kii se ohun ti iwọ se, tabi eyi, tabi tọhun, saa wa si ile isin, ki o si jẹ ọmọ Ijọ to dara. Bi o ba ge irun rẹ, kilo buru ni bẹ? Bi o ba wọ asọ penpe, to kun ọda oju, ti o si lọ si ilé-ijó, ọtin bia diẹ lẹẹkọkan, ko ni pa ọ lara, bi iwọ koba ti se laseju. Ni tootọ gan, o wumi ki ẹyin ọmọ maa mu ọtin, ki wọn ba a le kọ boya wọn nifẹ rẹ tabi bẹẹ kọ” Oun ni yẹn, ọlọrun, iran yii, iran buburu yii.

“Ọlọrun rere ni Ọlọrun”. Mo ti gbọ eyi to bẹ ẹ ti o ti mu ki ara mi kọ ọ. Ọlọrun jẹ Ọlọrun idajọ pẹlu. Oun kii se Baba agba kan ti ko lẹsẹ nlẹ ti eniyan lee maa ti kiri, ti awọn ọmọ ọmọ Rẹ ko si ni ẹsẹ kankan. O jẹ Ọlọrun idajọ ati Iwa Mimọ. O fidi eyi mulẹ ninu Ọgba Edẹni, pẹlu awọn Ọmọ Rẹ akọkọ. Bi iwọ ba kọja aala asẹ Rẹ, iku ni. Bakan naa ni loni.

52 Si kiyesi, O waasu iru ihinrere onimọ ijinlẹ, ti gbajumọ, ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ ati ọlaju fun Eefa, iyawo Adamu si gbagbọ. O si ti sase-yọ-ri ni kikun ẹni to pe ara rẹ ni Iyawo Kristi, Ijọ ti Adamu keji pẹlu iru ariyanjiyan bẹẹ. Bẹẹ ni.

“Ah, Ọlọrun ti dara ju lati se iyẹn. Kin ni, niwọn igba ti o ba lọ si ile isin. Bi iwọ ba ti gbagbọ”. Esu gbagbọ, kii se afẹnujẹ sugbọn o gbagbo gidi. A ko si gba a la. “Bi o ba saa gbagbọ” Hun!

O sọ fun iyawo keji tabi iyawo Adamu keji, ohun ti o sọ fun ti akọkọ. Bi eleyii, “Iwosan nipa agbara Ọlọrun, ko si ohun to jọ bẹẹ. A lee fi dani loju. Ko tii si ọkan ti a fidi rẹ mulẹ ri. Nipa itẹbọmi lorukọ Jesu yii, se iwọ ko mọn pe, emi ni alasẹ Ijọ ni?” O sọ wi pe,“ A ti fi ẹnu ọrọ naa jona ni Nikia, Roomu.” Nigba ti awọn ẹmi aimọ mẹta naa, jade lati ẹnu diragoni naa, awọn woli eke ati bẹẹbẹẹ lọ. “Awa gbagbọ ninu mẹtalọkan”. Mase wa siwaju Ọlọrun pẹlu iru ero yẹn laelae. “Ah, ko se pataki, bi a ba se itẹbomi ni awọn apele, 'Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ' Iyatọ wo, lo wa nibẹ?”

53 O ni iyatọ tobẹẹ ti Pọọlu fi pasẹ fun awọn baptisti kan pe wọn nilati tun itẹbọmi se ni Orukọ Jesu Kristi ki Ẹmi Mimọ to lee ba le wọn. Osi tun mu ki aposteli naa kigbe wi pe “Bi angẹli kan ba ti Ọrun sọ kalẹ wa, ti o si waasu ohunkohun to yatọ, jẹ ki o di ẹni ifibu”. Dajudaju, iyatọ wa nibẹ.

“Ko si ohun ti n jẹ ibaptisimu Ẹmi Mimọ ni ọjọ oni. Kiki awọn aposteli ni o wa fun. O si ti kọja. Ohun kan bi wolii? A o tilẹ mọn iyẹn rara. Isẹ iyanu? Ko ba imọn ijinlẹ mu. Malaki 4? Iyẹn wa fun iran miiran. Johanu 14:12? Ero kan lasan ni yẹn. Se o rii? Wọn si iyẹn tumọn ni. Ko tilẹ si ninu Bebeli akọkọ” Iru awọn ibajẹ bẹẹ. Ọrọ rirun. Nigba ti Ọlọrun Olodumare n sọkalẹ ni aarin wa, ti o si n fi Ọrọ rẹ da niloju pe, otitọ ni nigba ti Ọlọrun wi pe “Jesu Kristi, Jẹ ọkan naa lana, loni ati titi lae” O si n fi eyi da ni loju. Ẹmi Ọlọrun ni Olutumọ Ọrọ Rẹ. O wi pe, Oun yoo se nkan wọnyi ni opin ọjọ. “Imọlẹ yoo wa ni igba asalẹ” Imọle si wa, fun ifihan-fayeri-Ọmọ-Ọlọrun naa.

54 Oorun kan naa ti o nyọ ni ila oorun ni o nwọ si iwọ ọ rẹ. Wolii na wipe, “Ọjọ kan yoo wa ti a ko lee pe ni ọsan tabi oru.” O jẹ ọjọ baibai, pẹlu ikuuku, ti o subo oju oorun. Sugbọn o wi pe. Ni igba asaalẹ, Imọlẹ yoo tun wa lẹẹkan si“. Ọmọ Ọlọrun kan naa. Oun ni Alfa ati Omega. Oorun Ọmọ Ọlọrun kan naa ti o dide ni ila oorun aye ni ibẹrẹ, Oun naa ni a sọtẹlẹ lati tan ni akoko opin aye, nigba ti o ku diẹ ki aye parẹ. Emi ko mọn bi wọn se tumọn rẹ. Ọlọrun ni o n tumọn Ọrọ Rẹ. O n fida ni loju. Eyi ni irọle aye.

O ba ni ninu jẹ, sugbọn ijọ subu fun imọn ọpọlọ lasan lati ile ẹkọ ẹsin, ti oniwaasu kan sọ dipo ki o gba Ọrọ Ọlọrun Mimọ gbọ, ti a jẹri gbe.

55 Ẹyin oniwaasu ni gbogbo agbalaaye, nibikibi ti ẹ ba wa ti ẹ lee tako otitọ yi. Emi ko mu yin binu. Emi nba awọn ẹgbẹ temi sọrọ. Bi ẹ ba fẹ joko pẹlu wa, inu mi yoo dun fun ọ lati gbọ ọ. Nigba naa, ẹ fi eti si I. Se ẹ rii? Sugbọn emi kan n sọ fun wọn ohun ti wọn ti ri, mo si n fi han wọn, Ọlọrun nfi daniloju pe, otitọ ni. Se o rii? Eyi ni wakati naa. Ko nilo ki ẹnikẹni tumọn Rẹ. Imọn rẹ taye yii ko nii se pẹlu Rẹ. Iwọ ni oye ẹkọ iwe B. A, D. D., A, tabi ohunkohun ti o lee jẹ, ko ni itumọn kankan. Ọlọrun ni O ntumọn Ọrọ Rẹ funra Rẹ. O seleri Rẹ, Oun si ni yii.

Sugbọn nipa imọn ile ẹkọ ẹsin, iwaasu ijọ-ẹlẹkọ-adamọ ti jẹ ki gbobo aye wọ́ tẹ̀lé ẹranko naa, ti a wo ọgbẹ iku rẹ san Lati Roomu ti isin iborisa, o parada di Roomu ti Popu. Se ẹ ri ibi ti o n yọri si? O gba a gbọ.

Ijọ gba ohun ti esu sọ fun un gbọ.

56 Bẹẹ ni. Kiyesii! Awọn iyawo afẹsọna mejeeji gba imọn satani gbọ lodi si Ọrọ Ọlọrun. Iyawo Adamu gba imọn satani gbọ lodi si Ọrọ Ọlọrun. Iyawo Kristi pẹlu ti gba imọn satani gbọ ni iran buburu onimọn iwe aye yi, lodi si Ọrọ Ọlọrun. Si kiyesi, Nigba ti Eefa gba a gbọ, o ju gbogbo ẹda eniyan sinu iku. Iyawo ti ara Adamu, Okunrin naa ti aye, ki o to wà pẹlu iyawo rẹ, iyawo naa ti ju gbogbo ẹda eniyan sinu iku. Yala o ba iwadi imọn ijinlẹ mu tabi ko ba a mu, a n ku sibẹ, nitori Ọlọrun sọ wi pe, kiku ni iwọ yoo ku" Yala iwọ wa ninu Ijọ Edẹni mimọ, tabi ijọ mimọ tabi Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kan, tabi ohunkohun ti o lee jẹ, iwọ yoo ku ni ọjọ ti o ba ti saigbagbọ si ọrọ kan ninu Ọrọ Ọlọrun ti a fi dani loju nipa ijẹrigbe Ọlọrun si ọ. Lọjọ na ni iwọ ya ara rẹ kuro lọdọ Ọlọrun, kii se odidi ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun kan, sugbọn kiki ẹyọ kan ninu Rẹ̀. "Ẹnikẹni ti o ba fi ọrọ kan kun un, tabi ti o yọ ọrọ kan kuro" Ọjọ na lo di oku.

57 Kiyesii, Iyawo Adamu fa iku ara lati pa gbogbo ẹda eniyan. Iyawo Adamu keji, iyawo afẹsona Kristi ti ko gbogbo ijọ lọ sinu iku ti ijọ-ẹlẹkọ-adamọn naa nipa gbigba amin ẹranko naa nipasẹ awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọn nla-nla nipa ọgbọn eniyan ati imọn ijinlẹ. "Awa ni Baptisti, Awa ni Pirẹsibiteria. Awa ni Pẹntikọsita," ati bẹẹbẹẹ lọ. "Awa ni eleyi, a si ni dukia pupọ, Ijọba mọn wa. A wa kaakiri gbogbo aye". abb "Ọtọkulu, ati baalẹ ilu nla maa n wa si ọdọ wa. Aarẹ gan maa wa lati se maasi pẹlu wa, awa si maa n lọ si eyi, tọhun, ati ohun miiran". A si ti ko gbogbo aye lọ sinu iku tẹmi nipasẹ igbagbọ, ẹkọ-adamọ, gbogbo ijọ pata si ti ku.

O wi pe, "o maa ti nko gbogbo eniyan pọ bayii.

Jesu wipe, "Bi o se sẹlẹ ni ọjọ Noa, ninu eyi ti a gba ọkan mẹjọ la, bẹẹ ni yoo ri ni bibọ Ọmọ eniyan naa" "Ni ọjọ Lọti, ti a mu eniyan mẹta jade ni sodomu, ni ọjọ na" Bayii, ranti pe ẹgbẹ kan wa ti ko si ni Sodomu rara. "Sugbọn bi o se ri nigba naa, bẹẹ ni yo rii nigbati Ọmọ eniyan yoo farahan. Wo iru ọjọ yii, wo ibi ti a de bayi.

58 Bayii Ijọ naa ti mu ki gbogbo aye gba idari nipa eto ti a gbe kalẹ, nipa ẹkọ iwe, ati nipa imọn ijinlẹ. Mo n fi ọlọrun aye yii han fun ọ. Nigba ti iyawo yii, gẹgẹbi Eefa ti o ni Ọrọ Ọlọrun pẹlu rẹ. O seese fun un lati gba Ọrọ Ọlọrun gbọ, Sugbọn kin ni o se? Dipo ti oun i ba fi duro titi yoo fi gba Ẹmi Mimọ, o gba imọn ijinlẹ laaye lati fi daa loju pe, Ẹmi Mimọ wa fun kiki awọn ọmọ ẹhin Jesu akọkọ nikan. Dipo ti wọn i ba fi jẹ ki iwosan-nipa-agbara Ọlọrun ma a tẹsiwaju, nigba ti o yẹ ki o ma ji oku dide, ki o si maa se awọn isẹ iyanu naa, o ti gba satani laaye, labẹ iran okunkun to kun fun ẹsin lasan tirẹ, ki o mu Ọrọ Ọlọrun ki o si sọ fun un pe, iran miran ni o wa fun, oun si ti gba eke yii gbọ.

59 Nigba ti Bibeli wi pe, "Awọn isẹ ti Emi se ni iwọ yoo se pẹlu" Jesu sọ bẹẹ. "Ẹ lọsi gbogbo aye, ẹ si waasu Ihinrere fun gbogbo ẹda" Ẹda ni a si jẹ sibẹ. "Awọn amin wọnyi ni yoo tẹle olukuluku awọn ti o ba gbagbọ" Oun sì sẹ́ gbogbo iwọnyii.

O sẹ gbogbo agbara Ọlọrun, o si fi se pasi-parọ pẹlu ọgbọn ọpọlọ lasan, ti i se ero ti ẹranko naa nipa Bibeli. Nibiti awọn alufa paadi, awọn fada' mimọ (ti wọn n pe wọn), awọn Bisọọbu, awọn aake bisọọbu, awọn Pirẹsibiteria agbegbe, awọn alakoso gbogbogbo abb. ti fi itumọ ikọkọ tiwọn si, ti wọn si joko soju kan nibẹ, ti wọn ku bi i agogo mejila.

Ohun kan soso ti o ku ni opin ọjọ yii ni awọn afede-ajeji-sẹri-Ẹmi Mimọ diẹ pẹlu ariwo nla ti orin ati ohun elo orin ti wọn yi soke bi o base le pariwo to, ti wọn n sare soke sodo nile ijọsin, ti wọn nfede ajeji sọrọ, ti wọn si n pariwo, Wọn ni ifarahan iwa bi Ọlọrun sugbọn wọn sẹ agbara rẹ." Sọ fun wọn ki wọn se itẹbọmi ni Orukọ Jesu kristi, wọn yoo fi ọ rẹrin loju rẹ. Sugbọn pẹlu gbogbo eyi, Ọlọrun tẹ siwaju, O si n fi Ọrọ rẹ daniloju pe Otitọ ni.

60 Kiyesi, igi ti satani mu Eefa jẹ ninu rẹ ni igi rere ati buburu. O jẹ igi adalu. Bayii, wo ọjọ ti a n gbe ninu rẹ yii, nigba ti Ọlọrun n pe iyawo kan jade. O ti ni ijọ kan ti o jẹwọ wi pe, oun n se rere nigba ti oun jẹ ibi, nipa sisẹ Ọrọ naa. Igi adalu ni. Olee wipe, "Wọn ni awọn awujọ eniyan nla-nla. Wọn n ran awọn eniyan lọwọ. Ẹgbẹ Alagbelebu Pupa fọwọsi i. Bẹẹni gbogbo ile iwe, Ẹ woo!" Sugbọn, saa ti sẹ́ ọrọ kan pere. Ohun ti o nilati se ni yii, iwọ ku bi o ti wu ki o kun fun ẹkọ ọpọlọ lasan. Jesu wi pe, "Iwukara kekere sọ gbogbo iyẹfun di wiwu". Iwukara kihun, ba gbogbo ọrọ na jẹ. Ọrọ Ọlọrun kan soso ti a sigbe kalẹ, tí kò sí ni àyè Rẹ, ba gbogbo aworan naa jẹ. Ki a wa sọ pe, Ọwọ mi wa nibi ti ẹsẹ mi wa bayii? Se o rii? Ki a wa sọ pe eti mi wa nibi ti ọwọ mi yẹ ko wa nkọ Iwukara kiun, sọ gbogbo iyẹfun di wiwu. O wi pe, "Bawo niwọ se mọn wipe o tọ?" Oluwa nfi daniloju pe, otitọ ni. O n jẹrigbe e. O sọ ninu Ọrọ rẹ, lẹhin na O fi daniloju, pe O tọ. Bayi ni a se n mọn bi O jẹ otitọ tabi kii se otitọ. Saa ti sẹ́ ẹyọ Ọrọ kan lo nilo lati ku. Oni abajade kan naa ni iran yii, iku tẹmi, gẹgẹbi o ti fa iku ti ara fun gbogbo ẹda eniyan nigba naa.

61 Kiyesi bi satani se ri iran onimọn-ijinlẹ ti aye Noa ni mu, nipa titẹ si imọn ti ara wọn. Ha! Bibeli sọ fun wa ninu Iwe Owe, "Ma se tẹ si imọn ti ara rẹ" Bibeli tun wi pe, "Jẹ ki ọrọ eniyan gbogbo jẹ irọ, ki Ọrọ Ọlọrun jẹ otitọ" Sugbọn Satani, nipa imọn rẹ lati atetekose ninu ọgba Edẹni, o mu ki awọn eniyan tẹ si imọn ara wọn.

O si mọn, nipa awọn eroja-asara-lọsọ nla rẹ ti o ni nigba naa lọhun, o mu ki awọn obinrin lẹwa pupọ, to bẹẹ ti o mu ki awọn ọmọkunrin Ọlọrun ko subu sinu ẹsẹ, ki wọn si fẹ wọn. Bẹẹ ni. Awọn obinrin dara si, wọn lẹwa pupọ.

Iwọ mu eyi-keyi obinrin ti o ba ri loju popo loni. Ọpọ ninu yin ti ka itan. Ẹyin ko gbọ ọ nitori o saaju akoko temi. Peal O' Brien, ẹyin melo lẹ gbọ nipa rẹ? Dajudaju. Oun ni wọn pe ni obinrin to lẹwa julọ laye nigba kan. O fẹrẹ ma si ọmọbinrin ti o nlọ sile iwe loni, ti ko lẹwa julọ nilọpo meji. Tori kin ni? Ẹwa obinrin ni lati pọ si ni opin ọjọ. Wọn ti ge irun wọn, wọn wọ asọ penpe, ati bikini tabi ohun ti ẹ ba npe e. Wọn kun ọda si ete, oju ati awọn nkan wọnyi lati sọ wọn di ohun ti wọn ko jẹ. Se o rii? Sugbọn, nipa imọn ijinlẹ, wọn ti sawari awọn nkan wọnyi. Njẹ o mọn wi pe, owo ti wọn nna fun ẹsọ ara obinrin ni orilẹ-Ede Amẹrika, o to ilọpo meji, iye owo ti wọn nna le onjẹ lọ. Wadi eyii. Otitọ ni, fun ẹsọ ara.

62 Kiyesii, awọn ọmọkunrin Ọlọrun ri awọn ọmọbinrin eniyan", kii se awọn ọmọbinrin Ọlọrun. "Awọn ọmọbinrin eniyan, pe wọn lẹ wa" O si jẹ ki awọn ọmọkurin Ọlọrun subu sinu isina yii. Wọn si mu ninu awọn obinrin wọnyii, wọn si fẹ wọn laya. O si fa iran awọn asẹwo, gẹgẹ bi o se ri loni, bi o se ri ni Sodomu, bi a se sọtẹlẹ pe yoo ri loni. Nigbati awọn okunrin ati obinrin ọjọ oni nse pàsí-pà-àrọ̀ awọn iyawo wọn. Bi wọn ko ba fẹ iyawo wọn yii, wọn lee lọ si Reno Nevada, ki wọn kọ ara wọn ki wọn si fẹ obinrin miran ni isẹju mẹẹdogun. Awọn obinrin si lẹwa de ibi ti wọn fẹrẹ ẹ di ari-malee-lọ. Kin si ni? Esu ni. Se o rii? Satani si wa ninu ẹwa.

Kiyesii, a ko dari ẹsẹ yẹn ji wọn rara. Iran to lẹwa, to kun fun imọn-ijinlẹ yẹn, ni iran buburu ti Ọlọrun parun kuro lori ilẹ aye. Jesu wipe, bẹẹ gẹlẹ ni yoo ri lẹẹkan si nigba ti Ọmọ eniyan yo pada wa. Se otitọ ni yi?

Kiyesi Jesu wi pe, "Bi o ti ri ni ọjọ Noa, bẹẹ ni yoo ri, ni ọjọ wiwa Ọmọ eniyan naa", nigba ti gbogbo wọn gbiyanju lati gbeyawo... Kiyesi bayi, awọn ọmọ Ọlọrun fẹ awọn ọmọbinrin eniyan to lẹwa, Ọlọrun ko si fi igba kan dari ẹsẹ naa ji wọn.

63 Bi ẹkọ Balaamu se ri gẹlẹ ni yii. Ti o mu ki awọn ọmọbinrin moabu to lẹwa, ọlọgbọn ọpọlọ, onimọn ijinlẹ, pẹlu oju ifẹkufẹ, pẹlu ọda ikura ati atike ikunju, awọn obinrin ti Israẹli, ti wọn ti sisẹ, ti atẹlẹwọ wọn ti dapaadi, ti ko si lo ikunra ẹsọ ara kankan. Wọn fa awọn ọmọkunrin naa mọra, wọn si wi pe, "Ẹ jẹ ki a fẹ ara wa, ki a gbera ni yawo, nitori pe ọkan naa ni a saa jẹ." Irọ ni yẹn! Irọ ni, o si jẹ aseyọri esu lati mu ki awọn ọmọkunrin Ọlọrun gbe awọn ọmọbinrin eniyan ni iyawo. O jẹ irọ esu, fun Balaamu, Wolii eke ni lati sọtẹlẹ lodi si Mose, ẹni ti o gbiyanju lati mu awọn eniyan Ọlọrun duro ni ọkan, ki o si yatọ si aye. Sugbọn Balaamu kọ wọn pe, "O dara, ajọ gba Ọlọrun kan naa gbọ ni. A n se irubọ kan naa. A nse ohun gbogbo bakan naa". O sunmọ otitọ to bẹẹ ti yoo tan ayanfẹ jẹ ti o ba jẹ pe o seese." Se o rii? Jade kuro larin wọn ẹyin eniyan, ẹ ko ni ohun kan lati se pẹlu rẹ!

64 Kiyesi, ko see se ki Ọlọrun ki o tumọn Ọrọ rẹ fun iran buburu ti Kaini. Rara. Ọlọrun ki yoo tumọn Ọrọ Rẹ fun wọn. Njẹ Ọlọrun lee fun un ni imọn lati mu ki aye lẹwa, ki o kun fun imọ ijinlẹ ati ẹsẹ, to bẹẹ ti yoo fi paarun? Se Ọlọrun yoo se eyi, ki o jẹ ki aye lẹwa pupọ, ki o mu awọn ọmọ rẹ lẹwa, ti yoo wọ wọn lasọ to n fa ifẹ kufẹ, ti yoo mu ki awọn ọmọkunrin rẹ se ifẹkufẹ si wọn, ki wọn si se pansaga? Kinla? Se Ọlọrun yoo se nkan bi eyi? Awọn Laodikia ti o wa ni ihoho, to bọ asọ danu, ti wọn n sin ọlọrun aye yii, nipasẹ awọn ibajẹ wọn, ati ẹkọ, ati arekereke, ati ẹwa wọn! Bibeli wi pe, "Jade kuro laarin wọn mase jẹ alabapin ẹsẹ rẹ, ma si se gba iyọnu rẹ" Ọlọrun yoo rọ yinyin nla-nla lati sanmọn ni ọjọ kan, ọkọọkan rẹ yoo ni iwọn talẹnti kan, yoo si fi sọ wọn lokuta pa, bi Ọrọ rẹ ti maa n sọ pe Oun yoo se, awọn ofin Rẹ. O dara, bi Ọlọrun ba se ohun kan bi eleyi, ti o fi Ọrọ Rẹ han fun awọn eniyan bi eyi, yoo maa ja ara rẹ ni tanmọn-ọn. Ọlọrun kii se asiwere. Oun ni orisun gbogbo ọgbọn. Nirtori naa, se o ri ibi ti nkan yẹn ti wa? O wa lati ọdọ satani, o si jẹ ti satani sibẹ. Ijọ si ti gba a gbọ.

65 Se ẹ rii bayii ẹyin obinrin, mo n gbiyanju lati fi Ọrọ Ọlọrun han yin. Bibeli wi pe, "Bi obinrin ba ge irun rẹ, o tabuku orii rẹ ti i se ọkọ rẹ. Ọkọ rẹ si ni ori rẹ, pẹlu Ọlọrun. Nitori naa, o tabuku Ọlọrun ati ọkọ rẹ.

Bayii, eyi fi ẹmi naa han, ti o jẹ ori igbekalẹ ijọ aye yii. O fi ẹni naa ti o jẹ ori rẹ han. Satani ni, ni ifarahan okunrin alasẹ nla kan, okunrin onimọn, imọn titayọ. O mọn ju gbogbo awọn ti o ku. Ohunkohun ti o wu ki Ọrọ naa sọ, oun ni itumọn ti ara rẹ nipa rẹ, itumọn ti iran buburu yii.

66 Kiyesi eto rẹ lati kọ ẹgbẹ nla kan to-fi-ọrọ-eniyan-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun, eyi tii se Igbimọ-Ijọ-Agbaye, ki gbogbo agbaye baa lee sin in, ani ẹranko naa ni abẹ ajọsepọ gbogbo kristẹni. Se iwọ fẹ kaa bi? Ifihan 13:6 ati 8. Ohun ni ile isọ Babẹli ti ode oni.

Se iwọ ko ranti bi Nimurọdu, alagabagebe ni, se kọ ọwọn nla kan, ti o si mu ki gbogbo ilu to ku san owo ori fun un? Babiloni ati babeli jasi ohun kan naa. O kan yi orukọ rẹ pada o si tẹ siwaju. Ohun na ni Roomu, tii se Babiloni bayii. A si ti mu gbogbo aye wa si Babiloni, a si ti mu wọn wa nipasẹ Igbimọ-gbogbo-Ijọ-Agbaye ti yoo mu ki olukuluku wọn tẹriba fun un. Iwọ si ti gba amin ẹranko naa lai mọn ohun ti iwọ n se. Sugbọn awọn ti a ti yanfẹ yoo gbọ Ọrọ naa, yoo si jade kuro ninu Rẹ.

67 Bawo ni Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ se lodi si Ọrọ Ọlọrun to! Ọlọrun ko ni ọ̀kan ri, ko sisẹ ninu ọkan ri, bẹẹ ni ko ba ọkan sisẹ pọ ri. Mo fẹ ki onimọn itan kan fihan mi ibi ti wolii kan ti jade lati inu ijọ ri. Fihan mi ibi ti Ọlọrun ti bukun ijọ kan lẹhin ti o fi idari-eniyan-rọpọ-Ẹmi Mimọ. Ọlọrun pa a ti, o si ku. Pẹlu ọgbọn ọpọlọ lasan lati ọdọ esu, nipasẹ awọn asaaju wọn. Wọn kọ Ọrọ Ọlọrun, bi o se n dagba si iwọn pipe ti Kristi. Bayii, o ti de ori. Bi wọn se lodi si I to. Ya ara rẹ sọtọ kuro lọdọ Eefa ti ko gbagbọ, ẹyin ọmọ imọle irọlẹ aye.

Satani, ọlọrun iran yii, nipa imọn rẹ, o mu ki awọn eniyan jẹ ninu igi adalu rere ati buburu. Kiyesii, satani, nipa imọn rẹ, n mu awọn eniyan iran buburu yi lati jẹ ninu igi rere ati buburu. O sọ wipe oun nkọ ọlaju kristẹni to ga si nipa imọn rere ati ibi, Ọlaju kristẹni to ga ju. Sugbọn iyawo Kristi kekere yii jẹ Wundia Ọrọ naa, o si jẹ Agbo kekere, ko bikita fun imọn rẹ. O pa ara mọn kuro lọdọ rẹ.

Ẹ jẹ ki a sọrọ nipa rẹ fun isẹju kan. Iyawo Kristi tootọ n duro de Oluwa rẹ ati Ẹgbẹrun ọdun ti igbadun lẹhin ase igbeyawo pẹlu Ọkọ Iyawo tii se Ọrọ. Oun si ni Iyawo ti o jẹ Ọrọ naa.

68 Imọn aye ati ọlaju, ko ni ohun kan i se pẹlu Kristẹni tootọ. Wọn ko ni ohun kan to pawọn pọ. Ọlaju nwa nipa imọn aye. Gbogbo wa lo mọn eleyi. Imọn si wa lati Edẹni. O fi han nipa ohun ti o waasu ni Edẹni. Imọn si mu iku wa. Se ootọ ni? Kin ni o fa iku ninu ọgba Edẹni? Imọn. Sugbọn ko lẹ jẹ Imọn ti Ọlọrun, nitori naa, ti esu ni. Ah! Ah! Iyẹn dara! Imọn, imọn-ijinlẹ, ẹkọ-iwe ni idena to ga julọ ti Ọlọrun tii ni ri. Ti esu ni. Bayi, emi yoo gba awọn iwe kan (ibeere?) lori eleyi. Mo mọn bẹẹ. Mo n duro de wọn.

Wo ohun ti àsà ti sọ wa da nisisiyi. Se o rii? Wo ohun to ti se. Nibo la wa? A ti tẹ̀ sí awọn nkan wọn-ọn-ni, nipasẹ oye ti a ni nipa imọn ijinlẹ. O wi pe, “Ọlọrun nkọ, iwọ ro pe alaimọkan ni?” Ra ra! Ọlọrun yoo gbe ọlaju Tirẹ kalẹ laye nigbati o ba gba isakoso. Aye satani ni eleyi. Oun ni ọlọrun bayii fun imọ ijinlẹ aye yii. Sugbọn Ọlọrun yoo gbe iru Ọlaju Tirẹ kalẹ, koni jẹ iru ọlaju yii. Ranti iyẹn. Ko ni jẹ iru ọlaju ti a ni loni. Rara, yoo wa ni ibamu pẹlu Ọrọ Rẹ ati ipinnu Rẹ. Nitori pe, a oo pa ọlọrun iran buburu yii run, ati ijọba rẹ pẹlu rẹ.

69 Iran yi, onifẹ imọn ode oni, ko lee ni asaaju to dara ju eyi ti o ni yi lọ, tii se satani, ti o jẹ oludibajẹ Ọrọ Ọlọrun gẹgẹbi o ti bẹrẹ si se ninu ọgba Edẹni. O jẹ ẹni to nifẹ ẹsin, to si gbẹkẹle imọn tirẹ. Bi mo ti sọ tẹlẹ, (Iwe owe 3.5) wi pe, Awa ko gbọdọ tẹ si imọn ti wa. Wọn gbọdọ ni ọlọrun kan, nitori eniyan ni wọn sibẹ, oun se ohun ti wọn fẹ fun wọn. Gẹgẹbi wọn ti jẹ eniyan, nigba gbogbo, gbogbo eniyan. Nigba ti a de ibi yii, a ba awọn India ti wọn nbọ orisa oorun, abb. Gẹgẹbi eniyan, wọn nbọ ọlọrun kan. Nitorina, iran ọlọgbọn ọpọlọ giga yii, gbọdọ ni ọlọrun kan. Ọlọrun aye yii ti di imọn, ijọ-ẹlẹkọ-adamọn, imọ-ijinlẹ ti o ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, sugbọn o sẹ agbara Rẹ

70 Kiyesii, ọlọrun wọn se ohun ti wọn fẹ gẹlẹ fun wọn. Wọn se ifẹkufẹ fun ara.

Ohun ti o si fun wọn niyẹn, Wọn fẹ wọ asọ awọtẹlẹ obinrin (Bikinis), o gba wọn laaye lati wọ ọ. Se o rii? Bi wọn ba fẹ se eyi tabi tọhun, jẹ ki wọn see. Se o rii, bi wọn ba se eyi tabi tọhun, jẹ ki wọn see, ko si ewu rara, ohunkohun ti wọn i ba se, wọn n lọ si ile isin. Iya wọn jẹ Mẹtọdisti (Ijọ Eleto), Baptisti (Ijọ Onitẹbọmi), Pẹntikọsita (Ijọ a-fede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ), Pirẹsibiteria (Ijọ Awọn Alagba). Saa fi wọn silẹ, ọlọrun iran yi ni yi. O jafafa, o gbọn, o ni imọn ijinlẹ, ko nilo igbagbọ. Ko nilo ko fi ohunkohun daniloju. A ti fi gbogbo ẹkọ rẹ daa loju nipa imọn wọn. “O dara, awa ni Ijọ to tobi julọ ni ilu yii? - imọn wọn. ”Olusọ-Agutan wa ni oye iwe kẹnkẹ kẹnkẹ, D.D., PHD.“ Se o rii, ko nilo igbagbọ. Jẹ ki wọn gbe igbe aye wọn lọnakọna niwọn igba ti wọn ba ti wa sin in nipa ẹko adamọn wọn. Oju nla dudu kan wa nibẹ, sugbọn iwọ wo o. O nfi Ọrọ Ọlọrun se ẹlẹya, o nsọ àwọn ohun to lodi si Ọrọ naa. O si ngbiyanju nipa imọn wọn, lati fi daniloju nipa imọn ijinlẹ pe, Ọrọ naa kii se Otitọ. A! iru iran wo niyii ti a n gbe inu rẹ. Se o ri ọlọrun iran yii?

71 Kiyesi, Sugbọn Ọlọrun n duro titi ti irekọja awọn Amori ode oni yoo fi kun. Ma daamu. Ọlọrun yoo ni Mose Rẹ nigbati akoko ba to. Ẹksodu (ijade lọ) kan yoo sẹlẹ lọ si ilẹ ileri lọjọ kan. Mose kan yoo wa ti yoo pe jade, ti yoo si “Mu igbagbọ awọn ọmọ pada si ti awọn baba”. Yoo wa, ni ojọ kan. O wi pe, “O dara, wo o bi a ti n ni ilọsiwaju” Daju daju. Ago irekọja awọn ara Amori, kò tí ì kún. Yoo wa lọjọ kan, yoo jẹ ki wọn para wọn run.

Ọlaju ati imọn aye n dibajẹ Ọrọ Ọlọrun lati ba ifẹ inu wọn dọgba. Olukuluku Ijọ ẹlẹkọ adamọ ni o n se ohun kan naa. Satani si waasu ihinrere ti imọn rẹ ninu Ijọ rẹ.

72 Ẹgbẹ eniyan meji pere la sọrọ nipa wọn ninu Majẹmu titun. “Awọn ọmọ Ọlọrun ati awọn ọmọ esu” Njẹ iwọ mọn eyi bi? Se iwọ fẹ kọ Iwe Mimọ ti o sọ ọ silẹ? Johanu kin-in-in, 3.10. Mo n wo ibi ti mo kọ si bayi. O dara.

Ninu Efesu 2:2, a pe wọn ni “Awọn ọmọ alaigbọran”. Bi Eefa ti se saigbọran si Ọrọ Ọlọrun. Awọn ọmọ igbọran ati awọn ọmọ alaigbọran ko ni ohun kan naa papọ. Bawo ni Iyawo Kristi se lee ba ijọ-ẹlẹkọ-adamọ se papọ, nigba ti ọkan se igbọran, ekeji si jẹ alaigbọran? Bawo ni ọkan se lee jẹ Ọrọ naa ki ekeji si jẹ ọrọ idibajẹ? Bawo ni asẹwo ati obinrin oniwa rere se lee rin papọ ni irẹpọ? Wọn ko lee se e. Wọn ko ni idapọ rara. Jade kuro laarin wọn! Ti esu ni. Amin ẹranko naa ni. Gbogbo Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ ti nlọ si inu rẹ bayi. Emi

ko bikita eyikeyi ti o lee jẹ. Ọlọrun ko mu Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kan, sugbọn O n mu “Awọn eniyan kan fun Orukọ Rẹ”. Ijọ ẹlẹkọ-adamọ ko ni gba awọn otitọ yii, yoo gba aladori ẹnikọọkan ti o lee ri Ọlọrun, ki o wo Ọrọ Rẹ ki o si gba A gbọ, ki o ma si jẹ dukia ẹgbẹ-to-fi-idari-eniyan-rọpo-Ẹmi Mimọ. Sugbọn ti o gbe igbe-aye rẹ fun Ọlọrun, ki i se fun Ijọ rẹ tii se ọgbọn ọpọlọ ti bisọọbu tabi ohun kan ti wọn ti fi kọ ọ. Otitọ niyii.

73 Awọn ọmọ alaigbọran ati awọn ọmọ igbọran ko jọ ara wọn. Ọkan jẹ ọmọ Imọlẹ, ekeji si jẹ oru ati okunkun, iran buburu, iran buburu ti okunkun, to nlọ patí, ile-ẹgbẹ alaalẹ, ijó ibi, sibẹ wọn jẹ ọmọ ijọ. Eyi si tẹ ọlọrun wọn lọrun. Wọn ko ni idalẹbi nipa rẹ, ko si ohun ibi kan to da ọkan wọn laamu. “Kin-ni? ọkan mi ko dami lẹbi lati ge irun mi”. Obinrin kan wi pe, “Eyii ni ko damu ẹri ọkan mi”. Ko ni ẹri ọkan kankan bi ejo ko ti ni ibadi. Otitọ ni, ko tilẹ mọn ohun ti ẹri ọkan jẹ. A ti jó ẹri ọkan rẹ to bẹẹ ti ko tilẹ mọn ohun ti o jẹ mọn. Otitọ ni yii.

Wọn n tẹ Ọrọ Ọlọrun mọlẹ, wọn n wi pe, “Kin ni, awọn ohun atijọ ti a ti pati niyẹn. Ma lọ si ibẹ yẹn o. Wọn kan jẹ awọn alariwo lasan ni” Ha! Wọn ko mọn ohun to kere julọ nipa Ọlọrun. Bẹẹ ni. Otitọ ni. Wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun sugbọn wọn sẹ agbara Rẹ. Ẹ yẹra fun iru wọn. Nitori, iru-wọnyii lo nti ojule de ojule, ti wọn n dari awọn obinrin alaigbọn “A! Ọrẹ, o yẹ ki o se eyi. Mo ro pe oniwaasu rẹ ti ko gbọn yẹn. Bi o ba lee wọ asọ yii, iwọ yoo dun wo ninu asọ bikini yii” tabi ohun ti wọn n pe asọkasọ naa. “Iwọ, toba lee se eyi ati iyẹn, tabi ohun miiran. Kin-ni, mimu siga diẹ ko nii se eniyan ni nkankan. Emi naa nlọ sile isin, iwọ naa si mọn pe ijọ-ẹlẹkọ-adamọ mi ki gbẹyin rara laarin gbogbo ijọ” Mase gba opurọ to kunju-kunmu yẹn gbọ laelae. Irọ lo n pa fun ọ. Otitọ ni yii. Bẹẹ ni.

74 O tẹ ọlọrun wọn lọrun. O tilẹ gbosuba fun wọn fun iwa wọnyi, wọn tilẹ nifẹ rẹ fun eleyi. Á á à à. Wọn yoo ba ọ jiyan. Wọn yoo doju kọ ọ taara, wọn yo tahun si ọ nipa rẹ. Dajudaju, Satani dide duro taaara niwaju Jesu Kristi Ọrọ naa, o si gbiyanju lati sọ pe “A ti kọọ pe”. Nibẹ, a si ri I, Ọrọ Ọlọrun ti a ti jẹrigbe. O wi pe, “kuro lẹyin mi satani!” O saa rin lọ, O se ohun kan naa.

Bi ẹnikan se sọ fun mi ni igba kan. O wipe, “Bayii, bi iwọ ba gbagbọ ninu ibaptisimu Ẹmi Mimọ, pe o tọ, ti iwọ si gbagbọ pe o ni I, wa bu ifọju lu mi bayii” Oniwaasu kan si ni. O wi pe, “Bu ifọju lu mi, Pọọlu bu ifọju lu okunrin kan lọjọ kan.

Mo wi pe “Alagba, bawo ni mo se lee bu ifọju lu ọ, nigbati o ti fọju? Bawo ni mo se lee pa ọ nigba ti iwọ ti ku”

O wi pe, “Oju mi pe peperepe”

Mo wi pe “Oju ti ara rẹ riran, sugbọn iwọ si fọju sibẹ”

O dahun, “ko see se! Bibeli kii tumọn ohunkohun. Awa n sọrọ nibiti Bibeli ba ti sọrọ a si ndakẹ nibiti Bibeli ba ti dakẹ”.

75 Mo wi pe, “O dara, nigba ti Elija (Elisa) wa ni Dọtani, gbogbo awọn ọmọ ogun Syria wa yii ka. Iransẹ rẹ wa, o wi pe, Ah! Baba mi! Awọn Siria ti yi wa ka” Elija nu oju rẹ, o dide loju orun, o si wi pe, “Awọn to wa pẹlu wa ju awọn to wa pẹlu wọn lọ”. O wi pe, “Emi ko ri ẹnikẹni”. O wi pe, “Ọlọrun, la a ni oju”. Bayii, o fọju. O si wo kaakiri woli atijọ yii, ati lori oke kaakiri, o kun fun awọn Angẹli, kẹkẹ Ina ati ẹsin Ina“ O si rin jade sibẹ. Bibeli wi pe, O bu ifọju lu wọn. Fọju si kin ni? Si ara rẹ. O rin jade, o wi pe, se Elija ni ẹ n wa? Bẹẹ ni, awa n wa a” “O wi pe” wa, emi yoo fi ibiti o wa han yin. Elija n mu wọn lọ sọdọ Elija. Wọn fọju. Mo wi pe, “O mọn nkan ti emi yoo sọ fun ọ? Ohun naa gẹlẹ ti Oluwa mi sọ fun baba rẹ, ”Pada kuro lẹyin mi“ Hun!

76 Kiyesii, awọn ọmọ igbọran, ati alaigbọran, ko ni ohun kankan to pa wọn pọ. Awọn alaigbọran n sin ọlọrun wọn. Wọn wi pe, “Awa gba Bibeli gbọ” Bẹẹ ni. Igi adalu ni. Se ẹ rii, wọn fi ohun aye ati imọn aye kun un. Igi adalu satani. O mu rere ati buburu lati inu igi satani “Oh, awa gba ọrọ naa gbọ”. Dajudaju sugbọn kii se gbogbo Rẹ. Eefa pẹlu gba ọrọ naa gbọ sugbọn o gba satani laaye lati mu igi naa ki o si dibajẹ rẹ diẹ. Ohun ti o jẹ niyi. Ẹnikẹni ti o ba fi ọrọ kan kun tabi mu Ọrọ kan kuro ninu Rẹ. O si jẹ Ọkan naa, lana, loni ati titi lae!

Kiyesii. O dara.

77 Iran buburu yi jẹ ti okunkun, sibẹ o jẹ ti Ijọ. Wọn nifẹ ọlọrun wọn fun eyi, bi oun ti Ijọ. Wọn nifẹ ọlọrun wọn fun eyi. Bi oun se gba wọn laaye lati se ohun to wu wọn. Wọn ko ni idalẹbi. Ko si ohun to dawọn laamu niwọn igba ti wọn jẹ ọmọ Ijọ. Balaamu kọ́ ijọ ni ohun kan naa. “Ẹ jẹ ki a darapọ, ọkan naa ni wa ”Eyi ni ẹtan to gbẹyin. Ọlọrun ko dari rẹ ji wọn ri, fun gbigba irọ yii gbọ.

Ranti, ẹsẹ ti ko ni idariji ni, nigba mẹta ọtọọtọ ninu Bibeli, fun ẹnikẹni ki o fi ọrọ kan nipa itumọ tiwọn kún Ọrọ Ọlọrun lẹyin ti a ti jẹrigbe Otitọ. Ninu ọgba Edẹni, Ọrọ kan soso ni wọn fi kun un to fa iku. Nigba ti Balaamu fi ọrọ kan kun pe, “Ọkan naa ni gbogbo wa,” Ọlọrun ko dari rẹ ji Israẹli ri. Gbogbo wọn lo segbe ninu aginju, ayafi awọn mẹta ti Ọlọrun mu jade. Jesu wipe, “gbogbo wọn ni wọn ku”. Èyí nì ni ìyapa

ainipẹkun. Gbogbo wọn lo segbe, a ko dari rẹ ji wọn. Ẹsẹ ti ko ni idariji ni, a ko dariji wọn. Ẹ sa fun un, ẹyin ọmọ Imọlẹ igba asaalẹ.

78 Se ẹ tiri olórí iran buburu ti ode oni, ti o kun fun ẹsin yii? Esu ni, ti o mu igi rere ati buburu, ti o si n gbe kalẹ sibẹ. Kiyesii, o n mu iyawo rẹ, Ijọ ti o lẹwa naa lọ si igbeyawo Igbimọ gbogbo Ijọ agbaye. (Mo gbadun iyẹn) Iyawo rẹ to lẹwa to si kun fun imọn ijinlẹ pẹlu gbogbo awọn oye ẹkọ ti eniyan lee gba, Ph. D. lati inu Ijọ Church of Christ, Ph. D. lati Ijọ Baptisti, Pirẹsibiteria, Pẹntikọsita, abb. O ntan gbogbo wọn pẹlu ohun ẹ̀sọ́ ati ijọ nla nla, wọn nlọ si Igbimọ gbogbo Ijọ agbaye. “A jẹ ọkan naa”. A ko lee dari rẹ ji wọn laelae. Lati gba idanimọ ti Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ ni lati gba amin ẹranko naa. A ti kọni nipa rẹ yekeyeke nihin ju ki iwọ tun see. Sa fun un, ẹyin ọmọ, ẹ sa fun un. Se o rii? Ijọ to lẹwa, to si tobi, ti o wọ idanimọ igbimọ Ijọ agbaye, o wọ amin ẹranko naa. Wiwọ asọ penpe, iwọsọ aye, to nfa ifẹkufẹ? Ọda kikun oju, imu, gbogbo eyi jẹ awọn amin jijẹ ọmọ ẹyin fun esu, lati gba awọn ọmọkunrin ọlọrun mu fun igbeyawo. Lati fẹ ọmọkunrin to toju bibọ pẹlu ẹni itanu kan bi eleyi. Otitọ ni.

79 O wi pe, “Gige irun, kin ni iyẹn ni i se pẹlu rẹ” Arakunrin, Jẹ ki n duro ni isẹju kan. Mo ni imọlara pe ẹnikan tako eleyi. O si lee jẹ lati ibomiiran ti ẹrọ alatagba n gbe ohun iwaasu lọ. Fetisilẹ, irun ori fun obinrin jẹ ẹ̀jẹ́ Nasiri si Oluwa. Irun Samsoni jẹ ẹjẹ Nasiri si Oluwa. Nigba ti obinrin kan ba si ge irun ori rẹ, o sẹ́ ẹjẹ Nasiri rẹ̀ patapata pe oun jẹ iyawo Kristi. Nitori ninu ohun kan yii, o ba aworan naa jẹ. Bẹẹni! Nasiri jẹ “Ẹnikan ti a ya sọtọ fun ipinnu kan”. Se otitọ ni yii. A ya Samsoni sọtọ fun iran kan ati fun ipinu kan. Nitori naa, O ni irun gigun.

Obinrin ti o jẹ ọmọ Ọlọrun yoo jẹ ki irun ori rẹ gun, lati fihan pe, a ya oun sọtọ si gbogbo Ọrọ Ọlọrun. Bi o ba ge irun naa danu, emi ko bikita bi o se lee jo to, kọrin to, ko ti lẹ wa lẹgbẹ akọrin, ko fede miiran sọrọ, ko sare soke-sodo ninu ile isin, tabi o ni ọpọlọpọ awọn ẹgbẹ to n pese falaini, o ti ku. “Bayii ni Oluwa wi” nipa Ọrọ Ọlọrun. Kọrinti kin-in-in 14. Bẹẹni, o ti sẹ́ ẹjẹ Nasiri rẹ, o si tita ara rẹ, fun ọlọrun iran buburu ti ode oni. O see. Ki oju ti ọ iwọ obinirin ọmọ-luwabi tabi obinrin lasan yii!

Awọn afi-panpẹ-mu-awọn ọmọkunrin Ọlọrun, bi o se ri tẹlẹ. Bi Jesu ti sọ wi pe, “Gẹgẹ bi o se ri ni ọjọ naa, (awọn obinrin ni ẹwa, awọn ọmọkunrin Ọlọrun bẹrẹ sii fẹ wọn ni aya) bẹẹ ni yoo ri, nigba ti Ọmọ Eniyan yoo pada wa”. Ọlọrun wọn si ro wi pe ohun to dara pupọ ni, o si lẹwa, o ba imọn ijinlẹ mu.

Imọn, asa ilu-ibajẹ-Holiwuudu, ti wọn gbe kalẹ ni ile itaja rẹ. Bẹẹ ni. Gbogbo asakasa wọnyi.

80 Ijọ satani yi si fẹran nkan wọnyii pupọ! “Maa jẹ ko ye ọ pe, ”Mẹtọdisti ni mi“ ”Pirẹsibiteria ni mi“, Olusọ-Agutan wa lọ́pọlọ ju ko sọ nkan bi iyẹn” Ko ni ọpọlọ to lati sọ nkan ti Ọlọrun sọ niyẹn. Se o rii?

Ijọ ayé n bọ ọ́ ni, ó nífẹ ẹ rẹ̀. Ohun to nwa gẹlẹ! Iyawo aye yi ko ni darapọ mọn ohunkohun, Arakunrin, tabi ki o wọ inu ohun kan ti o gbọdọ yara rẹ sọtọ kuro ninu awọn Jẹsibẹli aye ode oni, nitori pe iwa ẹda to wa ninu rẹ gan ni yẹn. Bawo ni iwọ se lee se yatọ si iwa ẹda rẹ. Tani, nipa sise aniyan ni o lee fi ìgbọ̀n-wọ́ kan kun giga rẹ. Bi a bá bí ọ láti ga ní ẹsẹ̀ bàtà marun-un, iwọ ko lee ga ni ẹsẹ̀ bàtà mẹfa. Gẹgẹ bi irin isẹ ti o lee mu nkan gun si, ti Booth Clibborn se.

81 Ẹ fetisilẹ ẹyin okunrin, ẹyin ọmọ ita gbogbo yii. Bí a báá bí ọ lati jẹ okunrin, nigba naa, huwa bi okunrin gidi! Awọn osu irun ti o wa loju yin ti o kako bi ohun kan lati fa obinrin mọra. Kinla! Ẹyin iran ejo ti a ti dibajẹ rẹ yii. Ki lo se yin gan an? Ọlọrun mi yoo da orile-ede yi lẹjọ lojọ kan pẹlu ina. Yoo ri sinu okun. Wakati idajọ Rẹ ku si dẹdẹ. Gbogbo aye yoo parun.

Idibayẹ ẹsin! Idibayẹ eniyan, awọn okunrin ko tilẹ mọ̀n mọ́n bi akọ ni wọn tabi abo. Bẹẹni obinrin pẹlu. Awọn obinrin yoo duro pẹlu asọ isẹ okunrinn tabi sokoto penpe kan, awọn asọ to nfi gbogbo orikerike ara rẹ han. O si pera rẹ ni kristẹni. Asẹwo oju popo ni, ti esu nlo, ti esu n fun ni imisi rẹ, lati ran awọn ọmọkunrin Ọlọrun lọ si ọrun apaadi lati mu ọrọ Jesu Kristi sẹ. Emi ko ro lọkan mi lati sọ iyẹn, Ọlọrun ni o sọ ọ lọnakọna. Se o ri ibi ti ẹmi ẹlẹsin yi ti wa? Igi adalu naa.

82 O wi pe, “kin ni o buru ninu awọn asọ to ni sokoto to fun mọn ara tikẹ tikẹ yẹn - asọ awọn awa-kẹkẹ” abi ki lẹ npe. Bibeli wi pe, “Obinrin kobinrin to ba wọ asọ to jẹ ti okunrin, o jẹ irira ni oju Ọlọrun. ”Bayii ni Bibeli wi“ ni eyi. Obinrin kobinrin to ba ge irun ori rẹ sai bọwọ fun ori rẹ. Ẹsẹ tilẹ lojẹ fun obinrin lati gba adura bi o ba ti ge irun rẹ. Bibeli sọ bẹẹ, o kuna fun lati gbadura laarin ero lai bo ori rẹ.

Iwọ wi pe, “Emi de fila”. Iwọ alagagbebe, ti o kọ awọn obinrin ni iru ohun bi eyi ni! Nigba ti Bibeli wi pe, “A fi irun rẹ fun un fun ibori. Kii se fila kan ti eniyan kan se. Ohun ti Bibeli sọ niyii. Kii se ojuse mi lati mu ọ se e. Ojuse mi ni lati sọ ọ sita. Mase jẹ alaisootọ gẹgẹbi Bibeli ti wi. ”Ti o n fi ẹtan kọni ni Ọrọ Ọlọrun“, Ki iwọ lee mu ifẹ awọn ọmọkọmọ kan sẹ.

83 Mo ni ọrọ kan nihin-“ibi”. Mo kọ “Elvis” dipo “evil” (buburu). O fẹrẹ jẹ ọkan naa. Ọrọ naa Elvis tumọ si “Olongbo kan”. Ricky si tumọ si “ekute kekere”. Oun to ba pe ọmọ rẹ naa ni yoo jẹ. Bi o ba n pe ọmọ rẹ ni

awọn orukọ bi eleyii, yii pada kia, nitori ihinrere. Iwọ ko gbọ iru orukọ wọnyii ninu Bibeli tabi ni iran miran. Iran yii naa ni awọn orukọ yii wa. Bi igba kan ba wa ti awọn olongbo ati ekute ti wọn ti dabajẹ wa, iran yii ni.

Gbogbo awọn Adari-Orin (D.J) ati Olorin-aye wọnyi pẹlu ẹgbẹlẹgbẹ owo. Awọn ọmọde fẹrẹẹ ma lee duro lai ni ohun kan ti wọn ti bọ eti ti wọn ngbọ orin kan to ndun gbi, gbi gbi ni eti wọn. Wọn ti wa si ile mi nihin nijelo, awọn ẹnikan ti wọn fẹ kun ile mi. Mo wi pe, "mu ohun yẹn kuro ni ibi yii. Bi o ko ba lee sisẹ lai jẹ wi pe o ti ohun yi bọ eti, nigba naa, fi isẹ naa silẹ. Eyi mu ki ara mi ma balẹ rara, emi ko tilẹ lee duro sibi yii mọn. Awa ti ya ibi yii si mimọ fun Ọlọrun. Awa ko fẹ orin bugi-wugi radarada ti ọjọ igbẹyin yi nibi. Mo wi pe, "Pá á tabi ki o fisẹ naa silẹ"

Kiyesi, Sugbọn wọn jẹ ẹlẹsin. Bẹẹ ni, wọn lọ sile isin wọn a si duro ni ẹnu ọna ijọ ti wọn nfeti si orinkorin bugi-wugi.

84 Kiyesi pẹlu. Iyawo-Ọrọ ti Kristi naa n dagba pẹlu. Bi a ti ri ibi ti asodi-si-Kristi n lọ, bi o se bẹrẹ lẹyin lọhun, o si n bọ wa si orii rẹ bayii. Igbimọ gbogbo Ijọ agbaye yoo gbe de ori gbogbo oniwaasu. Ijọ kékerée nì naa n bọ pẹlu, Iyawo-Ọrọ ti Kristi lati gbogbo iran pẹlu nbọ wa si Orii Rẹ̀. Nitori, yoo lọ di ọkan pẹlu Ekeji Rẹ̀. Nigba gbogbo, ijọ ati gbogbo ohun to ku, nilati di ọkan pẹlu ohun kan. Alikama naa, gbogbo irugbin to ku nilati wa si orii rẹ tii se ohun to fi bẹrẹ ni atetekose, gẹgẹbi Kaini ati Abeli. Iyawo Ọrọ naa yoo pari si Ẹni naa tii se Ọrọ Ọlọrun ti-o-farahan-faye ri ninu iran buburu yii, ti a n gbe inu rẹ. Se o ri ibi ti o n pari si?

85 Laipẹ, satani yoo mu iyawo rẹ onimọ-ọpọlọ yi, yoo si gbe ẹni nla yii ga, tii se asodi-si-Kristi onipo giga julọ ninu ijọ, yoo si gbe e le ori itẹ kan, "Gbogbo aye yoo, si maa wọ tẹlee". Nigba naa, Kristi yoo de. Awọn mejeji ko si lee jọ wa papọ nigba kan na. A o si gba ijọba esu, a ó ò pá á run. Kristi si ni Ọrọ Ọlọrun. Obinrin si jẹ ara okunrin naa. Wọn kii se meji, ọkan ni wọn. Iyawo Kristi, Ijọ Ọlọrun, Ọrọ naa, jẹ awọn eniyan kan ti a pe jade lati ibi gbogbo nitori Orukọ Rẹ". Wọn yoo papọ di ọkan ninu ara Jesu Kristi. A oo si mu ijọba asodi-si-Kristi, a oo parun, Kristi yo si gba ijọba aye. Oun yoo si joko lori itẹ Dafidi Baba Rẹ, yoo si jọba lori aye fun ẹgbẹrun ọdun. Nigba naa, Oun yoo fi ijọ rẹ le Ọlọrun lọwọ "laisi abuku ati abawọn." Bẹẹni.

86 Bayi, kiyesi irun rẹ gigun, o jẹ majẹmu Nasiri si Ọrọ naa. Emi yoo gbe aworan iyawo Kristi kalẹ bayii. A ti fi aworan asodi-si-Kristi han, ati ibi ti o wa, nipa ẹsin, imọn ijinlẹ ati ni ọna gbogbo. Bayii, iyawo kekere, onirẹlẹ ti Kristi saa gba Ọrọ naa gbọ, Ẹni yoowu ki o jẹ. Awọn aladori ẹnikọọkan ni. Mo nireti, mo si gbagbọ pe ọpọlọpọ wọn ni o joko nihin lọwọlọwọ bayi ti ọpọ si n fetisimi. Mo si lero pe, emi pẹlu ati gbogbo yin ni a jẹ ara iyawo naa. Mo ni reti pe pupọ wọn ni. Yoo si jẹ gbogbo awọn ti a ti yantẹlẹ ni yoo wa nibẹ, nitori pe, iwa ẹda wọn ni. Ọrọ Ọlọrun nikan ni Ọrọ naa yoo dàpọ̀ mọ́n. Emi ko lee gba pẹlu ijọ-ẹlẹkọ-adamọn tabi idibajẹ kan. Wọn mọ ju bẹẹ lọ. Ọrọ naa ni. Se o rii? Ko lee da ohun miiran mọn. Alikama. O bẹrẹ gẹgẹbi alikama, yoo si gbó ni ipari gẹgẹbi alikama. Epo ko si lee jẹ alikama lae, sibẹ, a n bomi rin-in nipasẹ itamin ororo tabi imisi kan naa. Sugbọn, oun kii see alikaama. Bi mo ti sọ fun yin ni ijelo nipa igi kan ti o ni orisirisi ẹka ni ori rẹ.

87 Irun rẹ gigun, majẹmu Nasiiri fi han pe o ti ni majẹmu si Ọlọrun. Asọ ẹwa ti Ọrọ Ileri Rẹ fun iran ti a n gbenu rẹ ti a fi yii po, ti Ọlọrun si n jẹrigbe e pẹlu ara Rẹ. Heberu 13:8, "Jesu Kristi, ọkan naa lana, loni, ati titi lae." Gẹgẹbi Oun se jẹ ara Ọkọ iyawo tii se Ọrọ naa, o jẹ olootọ si I ni gbogbo ọna.

Woo bayii. Bi obinrin kan ti o lọkọ ba jade lọ ba okunrin miiran sere ifẹ, o yẹ ko o gba jade ni. O gbọdọ jẹ olootọ si okunrin naa nitrori pe o ti baa da majẹmu. Iyawo Kristi si ti ba A da majẹmu, Oun si ni Ọrọ naa. Ko tilẹ gbọdọ sẹju si ẹlomiiran. Obinrin ko gbọdọ sẹju si okunrin ti kii se ọkọ rẹ. Ko gbọdọ se amin Kankan sii tabi ki o fi imọnlara kankan han sii, nitori pe o jẹ iyawo kan patapata si ọkọ iyawo kan. Awa ko fẹ ikankan lara awọn igi adalu rẹ, awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọ rẹ. Jẹ olootọ si Kristi, Ọrọ naa. Oun yoo jẹrigbe e pe, otitọ ni.

Rara, alagba. Ko gbọdọ fi imọnlara kankan ti o lee fi ifẹ han sii okunrin miiran. Ko gbọdọ mọn ẹgbẹ rẹ, tabi ki o jẹ ki o gba ọ mu pẹlu apa rẹ tabi toju rẹ, ki o ba ọ sọrọ nipa ohunkohun. Iwọ fetisi ohun kan soso, "Awọn agutan mi mọn ohun Mi. Wọn ki yoo tẹle alejo. Kin ni ohun Rẹ? Ohun ẹnikẹni ni Ọrọ Rẹ, ohun si ni yii, Bibeli ni. A ko gbọdọ fi ọrọ kan kun un: tabi ki a yọ ọrọ kan kuro ninu Rẹ. Saa ti duro patapata pẹlu ohun kan naa. Wọn ki yoo tẹle ajeji ijọ ẹlẹkọ-adamọ kan.

88 Gẹgẹ bi o ti jẹ ara Ọkọ Iyawo, to jẹ olootọ si ni ọna gbogbo, to n duro de igbeyawo, o n di ọkan naa pẹlu Rẹ̀. Kii se ni igbimọ ijọ agbaye sugbọn ni awọsanmọ, ni ase igbeyawo. Eyi wa fun ijọ wa. A ti sipaya, a si ti fun un ni awọn ijinlẹ Bibeli Eledidi meje. Oun ri isiwere ti atannijẹ naa, ti o sunmọn otitọ to bẹẹ ti o fẹrẹ lee tan Ayanfẹ naa jẹ. O ri I.

Se o ri awọn ẹmi mejeeji to tako ara wọn ti wọn n sisẹ ni iran buburu yii? Njẹ o ye ọ bi? Ọkọọkan wọn ni o jẹ ẹlẹsin, ẹmi Kaini ati Abẹli. Ọkọọkan wọn n wa si ipari, wọn si ri bakan naa bi igba ti wọn kọkọ bẹrẹ, Ọkan n jọsin nipa ẹwa oju ati imọn aye, ati ẹkọ iwe ati imọn-ijinlẹ ati nipa iwa rere ati asa. Ekeji, nipa igbagbọ ti ifihan Ọrọ Ọlọrun. Awọn mejeeji lo wa ninu ile isin yii lowurọ yii. Otitọ ni yii.

89 Ifihan, tabi igbagbọ ninu Ọrọ Rẹ, kii sọ pe oun ni imọ kankan. Kristẹni to jẹ ojulowo. Wọn beere pe, “Iwọ ti gba oye iwe ti Ọmọwe (Dr.) bi? Ko ni jẹwọ imọn bẹẹ. ”Mo gba Ọrọ Rẹ gbọ“. Se o rii, kii sọ pe oun jẹ nkankan. Kii sọ pe oun jẹ ọmọwe. Kii se ọmọ ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kan, ẹgbẹ oselu kan, tabi ẹya kan. O jẹ ti Kristi. Iyawo Rẹ ni, Kii se iyawo ijọ lasan. O jẹ asẹwo. Bibeli sọ wi pe, O jẹ agbere ati IYA AWỌN AGBERE: gbogbo wọn si wa papọ lati di Agbere nla kan naa. Iru obinrin bayi jẹ obinrin ti ko jẹ olootọ si ọkọ rẹ ti o si n jẹwọ pe Kristi ni ọkọ oun, ti o si jẹ ti Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ. Iru jati-jati bẹẹ. Awa jẹ ti Kristi.

90 Sugbọn ni igbọran, Obinrin Igbagbọ kekere tii se Iyawo naa n gbe nipa igbagbọ. O jẹ ẹnikan nihin, ẹnikan lọhun, kaa kiri, gba Ọrọ Ọlọrun gbọ, o se igbọran, o n duro ni ifẹ fun ifẹsẹmulẹ ileri ti iran yii. O n fojusọna fun un. Oun jẹ ara Ọrọ naa, O si n se akiyesi igbe aye rẹ ki o lee fi Ọrọ na han fayeri. Eyin Ara, se ẹ ko ri eleyi ni? Mo lero pe eleyi ko fo yin kọja. Ara naa n duro (ti I se Ọrọ na) n duro de Iye naa (tii se, Ẹmi) lati fẹsẹ rẹ mulẹ tabi ki mu ki o wa laaye. Ohun ti o n duro de niyi. Ko si iye miiran ti yoo sisẹ ninu rẹ. Ko le di aaye ni ọnakọna miiran. Sibẹ o ni imọnlara rẹ pe O ti wa nitosi. O si mọn wi pe yoo sẹlẹ, lẹhin naa, o sẹlẹ o si taji. Ọlọrun wi pe, “Jẹ ki o wa” o si jadewa gẹgẹbi ti akọkọ se jade wa.

91 “Awọn ọmọ alaigbọran” Aigbọran ja si isọtẹ“ Mo wo eyi ninu iwe to n tumọn awọn ọrọ, ki o le dami loju. Isọtẹ lodi si kin ni? Lodi si Ọrọ Ọlọrun ti a sipaya, ti Ọlọrun si jẹrigbe pe o jẹ ododo. Gẹgẹ bi Kaini se sọtẹ lodi si isipaya Abẹli ti Ọlọrun jẹrigbe pe o jẹ ododo. Awọn Farisi, pẹlu imọn Ijọ-ẹlẹkọ-adamọn wọn nipa ohun ti Ọrọ Ọlọrun jẹ, Wọn yan awọn eniyan kan, wọn si sọtẹ lodi si Ọrọ Ọlọrun ti a ti jẹrigbe ti o si ti farahan faye ri fun ọjọ naa ti I se Jesu Kristi, wọn si pa A. Se Otitọ ni yii? Ohun ti awọn Ọmọ alaigbọran jẹ ni yii. O jẹ isọtẹ lodi si Ọrọ Ọlọrun. Bayii, wo ibi ti wọn wa? ”Oh, Awọn ọjọ isẹ iyanu ti kọja lọ, Jesu Kristi kii se ọkan naa mọn. Ko si nkan ti o njẹ Ibaptisimu Ẹmi-Mimọ. Ọrọ kọrọ ni gbogbo iwọnyi“ Se o rii. Isọtẹ. Wọn ko nilati sọ ohun meji. Ohun kan pere ni wọn nilati sọ. Isọtẹ ni yẹn. Wọn ko le sọ wi pe, ”Iwọ ko ni oju, iwọ ko ni eti. O nilati ni gbogbo ara. Gbogbo ọrọ naa. Se o ri.

Ẹmi Mimọ si kigbe pe, “Jade kuro laarin wọn, mase jẹ alabapin ẹkọkẹkọ Ijọ ẹlẹkọ adamọ rẹ” bi o se nfi Ọrọ Ọlọrun ọjọ oni rẹrin, ti o fi n se yẹyẹ. O si foju tẹnbẹlu Ọrọ Ọlọrun ti ọjọ oni. “A ko lee gan Ọlọrun” Saa ranti iyẹn. Yoo gba ere isẹ rẹ. Mase daamu. Yoo gba ẹsan rẹ. Bibeli, ni Efesu 4:30, (Gal. 6:7) ti o ba fẹ kọ silẹ. Efesu 4:30 wi pe, “A ko lee gan Ọlọrun ohun yi owu ti eniyan ba gbin, ohun ni yoo ka”, Wọn ko lee maa sẹfẹ, se yẹyẹ sọ gbogbo nkan wọnyi ki wọn si lọ bẹẹ lasan. Bi ohun ti eniyan gbin, yoo so, yoo gbo, wọn yoo si kore rẹ, bi akoko ba to“.

92 Oun ni Iyawo esu, ti o da asọ ẹsin rẹ bora pẹlu imọn rẹ to nifẹ ẹsẹ, fun iran buburu yii lati tan yin jẹ. A a a. Kikida ẹgbẹ awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọ to kun fun ẹmi itannijẹ nipasẹ imọn ijinlẹ ati ọlaju ode oni. (A o o pari lẹyin isẹju diẹ si. Mo ni lati duro laipẹ nitori a ko lee pari gbogbo rẹ tan). O sọ wipe oun nkọ aye kan to dara lati gbe. O wi pe, nipa ọlaju rẹ, Oun ti kọ awọn ile isin, ile-iwe, ile itọju alaisan, ile ikowe si, ati awọn iranwọ fun eniyan fun akoko diẹ, gbogbo rẹ lai si Ọrọ Ọlọrun. O ti see. O ti fi daniloju pe oun lee see. Awọn eniyan si ti fi daniloju pe oun lee see. Awọn eniyan si ti gba ẹtan rẹ gbọ. Bẹ ẹ ni alagba, awọn ile iwe, Ijọ-ẹlẹkọ adamọ, asa ẹgbẹ awọn to-n-wọsọ-dara-ju-awọn-miiran lọ, ẹgbẹ awọn eniyan-to-rijẹ-dara-ju-awọn-ẹlomiiran lọ. O tẹmi lọrun ki n wa ninu awọn to ni lati tọrọ jẹ, sugbọn ki n tọ́ pẹlu Ọlọrun, ju ki n maa jẹ adiyẹ dindin nigba mẹta loojọ, ki nsi jẹ ti asẹwo tẹ̀mí bi iyẹn.

93 Ranti pe akoko naa ti sunmọ etile, ti amin naa yoo wa. Ninu ki iwọ wa ninu rẹ tabi ki o ma si ninu rẹ. Yoo wa bi ole ni oru.Yoo ka ọ mọn inu ẹgbẹ naa ni, iwọ si ti wa nibẹ niyẹn. Ko si bi o se lee jade mọn nigba naa, o ti gba amin ẹranko naa. Jade kuro nibẹ! Angẹli kan sọkalẹ lati Ọrun pẹlu Imọlẹ Nla ni oju rẹ. O si kigbe ni ohun rara si awọn eniyan. O mi ilẹ aye. “Jade kuro ni Babiloni, nitori o ti subu. Mase jẹ alabapin ninu iyọnu rẹ, ẹyin eniyan Mi” Jade kuro ninu rẹ. Jade kuro! Se a ko ka ninu Ọrọ Ọlọrun laipẹ yii? 'Angẹli jẹ́ Òjíṣẹ́ Ohùn Ọlọrun' ti o n sọkalẹ wa. Se o rii? Kiyesi Ohun Ẹmi Mimọ, “Jade kuro ninu rẹ ki o ma ba a jẹ alabapin”

94 Bayii, o ti kọ gbogbo nkan wọnyi. O ti kọ awọn Ijọ nla nla. O ti kọ awọn ile iwe orisirisi. O n mu awọn eniyan naa, o si n kọ wọn ni ọlaju ti wọn sọ pe o dara si. Wọn si ti kọ wọn ni ẹkọ nipasẹ ọlaju ode oni, eyi to ti mu wọn wọ koto iku, nipa imọn to ti mu ki wọn jinna si Ọlọrun ati Ọrọ Rẹ. Se iwọ ko ri gbogbo ipinnu wọn ni? Se o rii ijọ? Ninu afẹfẹ lọhun, bi o ba ye yin ninu apejọpọ, ẹ sọ pe Amin. Awọn to ku yoo lee mọn iduro rẹ. Se o rii? Oun see. Ọlọrun aye yii ni. O si ti kọ awọn ile iwe giga, o ti kọ awọn Yunifasiti. O ti kọ awọn ile itọju alaisan. O ti kọ awọn ile ikowe-si ti wọn ti n kawe (library). O ti kọ gbogbo nkan wọnyii fun iranlọwọ eniyan fun akoko diẹ, ki o lee tan jẹ, ki o ba lee fi Ọrọ naa silẹ. Kin ni eyi si ti mu wọn lati se? Gbogbo ijọ agbaye lo ti ko lọ sinu iku, nitori Ọlọrun sọ wi pe, Oun yoo jó Agbere Nla naa run, ati awọn ọmọ rẹ pẹlu ina ayeraye. Jade kuro ninu Rẹ ẹyin eniyan! Mase jẹ ki o ka ọ mọ́n inú un rẹ̀. Iwọ jade kia kuro ninu ohun naa bi o se lee yara to. Nipa imọn ijinlẹ rẹ ni o fi se eyi lai lo Ọrọ Ọlọrun.

95 Ọlọrun ko gbe wa kalẹ gẹgẹbi Ijọ lati lọ da ile iwe silẹ. Ko se e ri. Ko sọ fun wa pe ki a lọ kọ ile itọju alaisan. Wọn dara. Bẹẹ ni. Ko sọ fun wa pe ki a lọ kọ ile ìkó-ìwé-sí(libraries). Rara alagba. Ko sọ bẹ ẹ ri. O wi pe, “Waasu Ihinrere”. Ihinrere si jẹ ifihan-faye-ri ati ifi-agbara-Ọlọrun-han nipa Ẹmi Mimọ. Pọọlu wi pe,

“Ihinrere tọ wa wa, ki i se nipasẹ ọrọ nikan, sugbọn nipa ifihan-faye-ri ati ifi-agbara-Ọlọrun-han nipa Ẹmi Mimọ”. Pọọlu wi pe, “Emi ko tọ yin wa pẹlu ọrọ nla nla ti ọgbọn eniyan, nipa imọn awọn ọmọwe nla kan, sugbọn mo tọ yin wa ninu agbara ati ifihan Ẹmi Mimọ, ki igbagbọ yin ma ba a wa ninu ọgbọn tabi imọn ti awọn eniyan aye yii, sugbọn ninu agbara ajinde Jesu Kristi. Nitori ti O wa laaye, ọkan naa lana, loni ati titi lae”. Ki Ọlọrun ran wa lọwọ lati gba ohun kan naa gbọ, ki Ọlọrun si jẹri gbe e bi O ti se maa n se látẹ̀hìnwá.

96 O n se e ki iwọ ma ba a ri ifihan tootọ ati igbagbọ Ọrọ Ọlọrun ti a n fi I han, ti a si n jẹrigbe loni. O n se eyi, nipa awọn ile iwe, ile iko-iwe-si, awọn iwe (litiresọ), awọn ile itọju alaisan, abb. Se o rii? O n de yin lọna lati ri Otitọ. O n tumọ nkan fun yin gẹgẹ bi o ti se fun Farao, ninu igbiyanju rẹ lati de yin lọna lati ri Itumọn Ọrọ ti a ti fẹsẹ Rẹ mulẹ gẹgẹ bi imọlẹ asalẹ yii ti a si ti jẹrigbe. O ti gbiyanju, nipa ẹkọ, imọn, awọn eniyan to jẹ ọmọwe, abb lati ri daju pe iwọ ko ri Otitọ naa. Ohunkohun to ba lee se ni o n se lati di ọ lọwọ ki o ma ba a bojuwo Otitọ yii rara, ki o ma ba a ri Jesu Kristi. Bawo lo se mọn pe Jesu Kristi ni? Oun ni Ọrọ naa. Oun si ni Ọrọ Ọlọrun fun iran yii. Oun si wi pe ohun yii yoo sẹlẹ ni iran yii, ohun si ni yii to n sẹlẹ yii. Se o rii? O ti sa gbogbo ipa rẹ ki iwọ ma baa ri Otitọ yii. Gbogbo orukọ buburu ni yoo pe e bi o ba ti lee se to. Yoo pe ọ ni, “gbara-yilẹ-mimọ” ati gbogbo nkan bẹ ẹ. O pe Jesu ni Belsebubu. Bi wọn ba si pe Oluwa ile ni Belsebubu, kin ni wọn yoo pe awọn ọmọ ẹyin Rẹ?

97 O n gbiyanju lati de ọ lọna ki iwọ ma ba a ri itumọn Ọrọ Ọlọrun tootọ. Ki i se itumọn ti oun n se, ti o n sọ pe, o tumọn si eyi tabi tọhun. Ọlọrun wi pe, “Mo seleri ni opin ọjọ, lati ran Malaki 4”. A ko ni lati tumọn eyi. Ọlọrun ti tumọn rẹ. O wi pe, Bi o si ti ri ni ọjọ Lọti, aye yoo wa ni ipo Sodomu, ati ni akoko naa, Emi yoo se ifihan Ọmọ eniyan naa. A ni orisirisi ifarawe ati ohun gbogbo bẹẹ, sibẹ a ni ojulowo pẹlu. Se o rii? O wi pe Oun yoo see. O wi pe asodi-si-Kristi yoo dide, yo si fẹrẹẹ tan awọn ayanfẹ jẹ bi o ba seese. Sugbọn O wi pe, “Fi wọn silẹ. Jẹ ki wọn tẹsiwaju. Isiwere wọn yoo farahan. Tori kin ni? Idanwo nipa Ọrọ naa yoo fi Otitọ han. Se o rii? Nigba ti o wa si Ọrọ yii, ”Ti o ti wa lati ẹyin wa………Ah, Emi ko gba 'iru ẹranko-to-pada-dejo' gbọ, emi ko gba eyi tabi omiiran“. A ko tii fihan ri. Rara.

A ni lati danu duro laipẹ, nitori pe agogo mejila ti lu.

98 Kiyesi, o n gbiyanju lati de o lọna ki iwọ ma lee ri itumọn Ọrọ ti iran yii, ti Imọlẹ asalẹ ti a n tumọn. Kin ni O tumọn si? Akoko ijade-lọ ti sunmọle. Ọlọrun n bọ wa lati mu Un. O daju gan an. Se o rii?

Bayii, mo fẹ beere ibere kan lọwọ rẹ. Nigba ti agogo mejila ti kọja isẹju marun-un; A o o tẹsiwaju lalẹ yii. Njẹ iwọ ri ọlọrun iran yi bayii? Njẹ iwọ gba eyi gbọ? Ẹ rii, ijọ-onimọn-ọpọlọ ati onimọn-ijinlẹ? Gbogbo aye lo ti di ara rẹ, (woo) gbogbo ijọ-ẹlẹkọ-adamọn. Iwọ wi pe, “kristẹni nimi” “ijọ ẹlẹkọ-adamọn wo ni tirẹ”. Bi mo ba jẹ ti ijọ-ẹlẹkọ-adamọn, a jẹ wi pe, emi kii se kristẹni. Bayii ọrọ nla niyii, sugbọn otitọ ni. Mo sẹsẹ sọ ohun kan laipẹ yii, pe imọn-eniyan, imọn-ijinlẹ, ati igbagbọ kristẹni ko ni idapọ kankan. Ọkan jẹ ti esu, ekeji si jẹ ti Ọlọrun. Ohunkohun to ba ti sẹ́ Ọrọ Ọlọrun, takete sii. Se o rii?

Bibeli n pe wa ni opin aye yii, pe ki awọn kristẹni jade kuro ninu agbere naa tii se igi-adalu rere ati buburu.

99 Dajudaju, o ni ohun rere. Se ẹnikẹni lee sọ pe ile-itọju-alaisan(Hosipitu) jẹ ibi? Rara alagba. Ile-ikawe-ti-a-kowe-si (laibiri)? Rara. Imọn-ile-iwe? Rara. Sugbọn se o rii, o n fun wọn ni awọn nkan wọnyii lai si Ọrọ Ọlọrun nibẹ. Se ẹ ri bi o ti kun fun itanjẹ to? O n fun wọn ni ile isin lati lọ, ijọsin lati se, ọlọrun to joko lori itẹ kan. Bibeli sọtẹlẹ nipa rẹ.

Bayii, iwọ jẹ ọkan ninu awọn ara meji yii. Awọn mejeji lo wa lori ilẹ aye bayii. Bẹẹ lo ti se maa n wa lati ipilẹ wa, bẹẹ ni yoo si ri titi Jesu yoo fi de, ti a oo si pa ọkan run ninu wọn. Iwọ jẹ ọkan ninu ẹgbẹ mejeeji bayi. Iwọ ti darapọ mọn ọkan ninu wọn, tabi ki a bi o sinu ekeji. Se o rii? Ọkan ninu wọn, o jẹ́ ara rẹ̀ nitoripe a bi ọ sinu Rẹ̀. O nilati jẹ ara Rẹ. Se mo lee sọ pe apa mi kii se ara mi? Gẹgẹ bẹẹ ni ko seese fun mi lati sẹ́ Ọrọ Ọlọrun kankan bi mo ba jẹ ara Ọlọrun. Mo jẹ ara William Branham. Mo jẹ ẹya ara pupọ. Olukuluku ẹya ara wọnyii si jẹ ara mi. Ọkọọkan Ọrọ Ọlọrun ni o nilati ba ẹmi mi mu, ba ọkan mi mu, ba igbe aye mi mu. O nilati ba awọn ero mi mu. Bi ero inu mi ba lodi si Ọrọ naa, nigba naa, Ẹmi Ọlọrun ko tii ma a gbe inu mi. Otitọ niyii. Ko lee sẹ́ ẹyọ Ọrọ Rẹ kan.

100 Iwọ jẹ ọkan ninu awọn ara meji naa. O nilati jẹ bẹẹ. Yala ki o jẹ ipa kan ninu Ọlọrun tii se nipa Ọrọ naa, tabi ki o jẹ ara satani nipa ijọ. Gbogbo agbaye ni yoo si jẹ ọmọ ijọ kan tabi omiiran, o n sin ọlọrun kan. O nilati maa sin ọlọrun imọn. Iwọ si gbẹkẹle ohun ti o gbọ nipa imọn, iwọ gbẹkẹle ohun yii, ohun yẹn tabi ohun miiran. Tabi ki iwọ gbẹkẹ rẹ le Ọrọ Ọlọrun, nipa igbagbọ, ti o si n reti Rẹ lati wa jẹrigbe ki O si mu ki O wa si imusẹ.

Ijọ Ọlọrun tootọ n wọna fun bibọ ọjọ ayọ ti Ẹgbẹrun Ọdun naa.

Nigba ti Oluwa wa yoo mu Iyawo lọ sile.

Ah! Ọkan mi kun fayọ bi mo se n sisẹ, sọna, gbadura.

Nitori Oluwa wa n padabọ wa saye lẹẹkan si.

Oluwa wa n padabọ wa saye

Oluwa wa n padabọ wa saye

A oo gbe satani de f'Ẹgbẹrun ọdun, ko ni si danwo mọn.

Lẹhin ti Jesu ba pada wa saye.

101 Ẹyin eniyan orilẹ-ede Amẹrika, nibiti Isẹ́ Ohùn Ọlọrun yii n jade lọ si bayii. Sa asala kiakia bi o ba se lee tete yara to. Sa fun iran imọn-ijinlẹ ti a n gbe inu rẹ yii. Sa lọ sinu Ọrọ Ọlọrun. Iwọ, emi, ẹnikẹni, ko si ẹniti o mọ̀n ọ́n. Ko si ẹni ti o lee fidani loju. Ọlọrun ni O n fi Ọrọ Rẹ daniloju. Ko si ẹni to ni ẹtọ lati tumọn Rẹ. Iba se emi, tabi ẹnikẹni, ko si ẹni to ni ẹtọ kan. Ọlọrun ni O n tumọn Ọrọ Rẹ. O se ileri naa. O sọ wi pe Oun yoo se eleyi ni opin ọjọ yii. Ni opin ọjọ wọnyii, ọlọrun iran buburu yii yoo fọ awọn eniyan loju, pẹlu imọn ọpọlọ lasan rẹ, pẹlu igi adalu rere ati buburu ti o n fun awọn eniyan. Ẹ wo o bayii, Ijọ-ẹlẹkọ-adamọn naa lati Ìgbà-òkùnkùn-ayé, ati saaju Àkókò-òkùnkùn-ayé yoo wa pari bayii sinu okunrin alagbara kan, satani ti o wi pe, “Emi yoo gbe ara mi ga ju awọn ọmọ Ọlọrun lọ, wọn yoo si feti si mi”. “Oun yoo si joko ninu Tẹmpili Ọlọrun, awọn ọmọkunrin Ọlọrun yoo si subu fun”

102 Kin ni idi rẹ ti ọmọ Ọlọrun yoo fi wi pe, “o dara, iyawo mi kii se bẹẹ, o jẹ ẹni rere abb” Tẹsiwaju, maa ni so. Iwọ wi pe, “O pe wọn ni awọn ọmọkunrin Ọlọrun” Bẹẹ ni. Okunrin, eyi owu ti I baa jẹ ninu wọn, a da a ni aworan Ọlọrun. Obinrin si jẹ amu-jade ninu okunrin, kii se aworan Ọlọrun. Bẹẹ ni. Nigba ti awọn ọmọkunrin Ọlọrun ri awọn ọmọbinrin eniyan pe wọn lẹwa, wọn mu awọn obinrin funra wọn. “Bi o si ti ri lọjọ Noa, bẹẹ ni yoo ri nigba bibọ Ọmọ Eniyan naa”. Woo bayii, bi iwọ ba fẹ mọn ipo ti ijọ wa, wo ipo ti awọn obinrin wa, se o rii, nitoripe, oun ni ijọ. Kiyesi ohun ti awọn obinrin n se paapaa ni iran buburu yii.

Wo o, ko si ilu ti o kun fun òùn-rorò, asebi ati asẹ́wó bii Nasarẹti, sibẹ, lati inu rẹ ni Ọlọrun ti yan wundia kan. “Njẹ ohun rere kan ha lee ti Nasarẹti jade wa bi? Ati lati inu iran buburu yii, nibiti ọlọrun iran yii ti fọ wọn loju, pẹlu ẹkọkẹkọ ti awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọn. Lati inu iran yi gan an ni Ọlọrun ti n yan 'Awọn eniyan kan fun Orukọ Rẹ.

B'o tilẹjẹ pe a kọ̀ wọ́n a si foju rena wọn,

Lọjọ kan Ọlọrun yoo mu awọn Ayanfẹ Rẹ wọ ẹnu ọna naa

Eyi si niye lori ju ohun gbogbo lọ.

Nigba naa, a oo kọrin, kigbe, jó káàkiri

Ọdọ-Aguntan yoo nu omije wa nu

Awa yoo ni ọ̀sẹ̀ ìpadà-bọ̀wálé aláyọ̀

Ni ẹgbẹrun mẹwa ọdun to saaju (Otitọ ni)

Awọn eniyan iyanu kan fun Orukọ Rẹ (Se Otitọ niyii?)

Bi aye tilẹ kọ wọn, foju rena wọn. Lọjọ kan Oluwa yoo mu

Awọn Ayanfẹ yii wọ ẹnu ọna Ilu naa (ninu ijade-lọ naa)

Eyi si ju ohun gbogbo lọ fun mi.

103 Mo ti bẹrẹ si di arugbo bayii, ọjọ aye mi si ti n tan lọ. Oju mi bẹrẹ si di baibai. Fitila aye mi ti n jo lọ silẹ. Emi ko bẹru okunkun naa. Nitori mo fẹ sọ pẹlu Pọọlu pe, “Emi mọn Ọn nipa agbara Ajinde Rẹ. Ibi yoowu ki wọn sin mi si, yala mo ri sinu okun, tabi a jo ara mi ninu ina, tabi kiniun jẹ ẹran ara mi, Oun yoo pe orukọ mi, emi yoo si dahun. Amin. Ẹ jẹ ki a gbadura.

Bi a ba rí nihin yii, tabi nibikibi ti ẹ ti n fetisi iwaasu yii, ni gbogbo orilẹ-ede yii. Ni gbogbo ile isin yin, ẹgbẹ kọọkan, tabi gbọngan ijọsin kaakiri, ibikibi ti ẹ joko, bi ẹnikẹni ba wa. A a a. Jẹ ki n rọ ọ, jẹ ki n bẹ ọ, gẹgẹbi iransẹ Ọlọrun fun Ihinrere, jẹ ki n bẹ ọ ni Orukọ Jesu Kristi, ẹ sa fun ibinu to wa fun iran buburu yii! Mase sin ọlọrun iran buburu yii. A! mo mọn pe iwọ wi pe, “O dara, wọn n se daradara”. Bẹẹ gẹlẹ ni, igi adalu ni. Iwọ ko lee da imọn aye pọ pẹlu Ọrọ Ọlọrun. O jẹ Ọrọ ti a nilati gba nipa igbagbọ, ki i se imọn. Ko lee ye ọ, sugbọn gba A gbọ. Iwọ sọ wi pe Otitọ ni, nigba naa, gbe nipa Rẹ. Oun gbogbo tí Ó beere pe ki o se niyii. Bi ẹnikẹni

ba wa nibi ninu ipejọpọ tiwa yii, a ko lee pe yin wa siwaju fun adura nitori pe ko si aye. Tabi nibikibi ti Ohùn naa lọ si. Bi ẹnikẹni ba wa lọhun ti ko mọ Ọn.

104 Ah! Ẹyin obinrin, mo ti ba a yin wi lowurọ yii. Ki i se emi. Mo saa tun Ọrọ naa sọ ni. Gige irun, wiwọ awọn asọ kekeke, wiwọ asọ to n fa ifẹkufẹ, se iwọ ko mọn pe ẹmi to n misi ọ lati se nkan wọnyii jẹ ẹmi esu ni? Iwọ lee mọn ninu agọ ara rẹ, arabinrin ọwọn, sugbọn ninu ọkan rẹ se o ko ri iru ẹmi to n dari rẹ ni? Njẹ Ọlọrun yoo jẹ ki ọmọbinrin Rẹ mura lọna ibajẹ lati tan ọmọkunrin Rẹ sinu ifẹkufẹ, lati mu ki awọn mejeeji dahun fun sise pansaga? Njẹ yoo se bi arabinrin? Beere ibere yẹn lọwọ ara rẹ. Rara. Ko see se ni igba ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun mẹwa. Mase ka eyii ni si Ọlọrun lọrun.

Arakunrin, Se Ọlọrun ti fun ọ ni ẹmi aye yi tobẹ ẹ ti iwọ ko mọn pe eyii ni kuna? Se o ti fọ ọ loju nipa iwa ijọ, ijọ-ẹlẹkọ-adamọn, ẹkọkẹkọ, abb to bẹ ẹ ti iwọ ko lee ri i pe Ọlọrun n jẹrigbe Ọrọ Rẹ, O si n mu Un sẹ? Se isẹ rẹ, ọga rẹ, iyawo rẹ, awọn ọmọ rẹ, ijọ rẹ, tabi ohunkohun ti ya ọ nipa kuro ninu Ọrọ Ọlọrun tii se Orisun Iye kansoso to wa. Sá fún un arakunrin mi! Mo nifẹ rẹ pẹlu ifẹ Ọlọrun. Emi ko bọla fun eyikeyi ninu awọn arakunrin mi ju iwọ lọ, rara. Bi mo ba se bẹẹ, emi yoo se ojusaaju eniyan. Emi ko sọ nkan wọnyii lati mu ọ binu. Mo fi nkan wọnyii han, mo si sọ wọn nitori pe, wọn wa ninu Ọrọ Ọlọrun. Gẹgẹ bi iransẹ Ọlọrun, pẹlu ifẹ Ọlọrun ni ọkan mi, mo sọ nkan wọnyii fun yin, ki ẹ le rii ki o si yee yin. O see se ki ẹ mọn ọn, bi emi ko ba sọ ọ fun ọ. Se iwọ yoo sa fun un loni? Bayii, nibi gbogbo kaakiri ti ẹ wa, ẹ jẹ ki a tẹriba.

105 Ọlọrun Ọwọn, awọn asọ inuju kekeke ni a kojọ siwaju mi yii. Awọn eniyan n se aisan. Mo gbe ọwọ mi le awọn asọ wọnyii, pe ki O wo wọn san. Mo si gbẹkẹ le Ọ, Oluwa, pe isin to ga pupọ yoo wà lalẹ yii, pe agbara Ọlọrun yoo wa nibẹ, pẹlu awọn Isẹ amin ati Isẹ iyanu.

Bi a se n gbọ awọn abajade lati inu awọn ipade diẹ ti a ti se sẹyin, bi o se lagbara to, awọn ohun to sẹlẹ! Mo gbadura, Ọlọrun wa ọwọn, pe ki O fun wa ni ilọpo meji lalẹ yii. Mo beere fun un pẹlu ọkan otitọ, Oluwa, nitori pe o jẹ ifẹ mi fun Ọ, ati Ọrọ Rẹ, ati awọn eniyan. Fi fun wa Ọlọrun wa ọwọn.

Bi a ba si ri ẹnikan ti o saisan ni gbogbo ibi ti a korajọ si kakiri orilẹ-ede bayii, ti yoo si lọ saaju isin alẹ yii, nihin tabi nibomiiran tiwọn wa, mo gbadura fun wọn pe ki O wo wọn san. Bayii Oluwa, fun iwosan to ga julọ! Bi Iwọ ba wo ara wọn san kuro ninu jẹjẹrẹ, ikọ efee, otutu aya, tabi ohun miiran, ko si iyemeji pe wọn yoo tun saisan nigba miiran, bi wọn ba pẹ si laye. Nitori ara wọn si wa labẹ ẹgun ẹsẹ naa. Sugbọn jẹ ki wọn ni iwosan giga naa, tii se iwosan ọkan wọn, ti yoo sọ wọn di ẹda titun, lati re iku kọja si Iye, ki agọ ara yii si maa duro de irapada ara naa lẹyin ti a ra ọkan pada. Fi fun wa, Oluwa.

Jẹ ki wọn sa fun ijọ-ẹlẹkọ-adamọn ati ẹkọkẹkọ. Ọlọrun, laarin awọn ẹkọ-kẹkọ ati ẹlẹkọ-adamọn wọnyii, mo ti pade diẹ ninu awọn arakunrin to dara julọ. Ọlọrun, bawo ni mo se lee sọọ kiwọn lee rii, ki wọn lee ri Ọrọ naa. O n se mi ni kayeefi. Sugbọn, èmí tún mọ̀n pé, Iwọ sọ wi pe“ (laika bi wọn se lee jẹ ẹni rere, ọlọkan tutu, ati oniwa pẹlẹ to) ko si ẹni to lee wá lai se pe Baba Mi lọrun ba pe e. Gbogbo awọn ti Baba si ti fi fun Mi, wọn yoo wa” Ati pe Oluwa, mo mọn lọkan mi pe, mo ni ojuse lati sọ Otitọ. Kii sii se, gẹgẹbi Pọọlu ti wi, “Fifi ọwọ ẹtan mu Ọrọ Ọlọrun” pẹlu ẹko adamọn ti ijọ-ẹlẹkọ-adamọ, ti wọn se adalu rẹ pẹlu imọn rere ati buburu, sugbọn pẹlu ọkan to si silẹ ati Ẹmi Mimọ. Ọlọrun, se bẹẹ fun wa. Gba gbogbo ọkan wọn la.

106 Bayii, pẹlu ori wa ni titẹba, ti a si di oju wa. Kii sii se si mi. Emi ko lee sọ bayii pe, “Ko se pataki si mi, yala o see, tabi o ko see” O se pataki si mi. Mo nifẹ rẹ. Mo si lero pe iwọ ko ro wi pe, nitori mo ni lati sọrọ lile….. gẹgẹbi Pọọlu ti sọ, Mo fẹ ki emi wa pẹlu yin, ki emi lee yi iwa mi pada“ Kii se wi pe oun ko fẹran wọn, o nifẹ wọn. Gẹgẹbi Jesu se nilati ba wọn wi, lẹhin naa O ku fun wọn. Se o rii, ”Baba dariji wọn, wọn ko tilẹ mọn ohun ti wọn n se“. Lati ro wi pe, eniyan kan to fẹ se ohun to tọ, to si n gbiyanju lati tọ, ki a si ri esu naa. Esu yii ni mo lodi si, to n fọ awọn yii loju.

107 Orilẹ-ede yii yẹ ki o kun fun Ogo Ọlọrun bayii, bi a ba wo ohun ti o ti sẹlẹ ninu rẹ ni opin ọjọ yii. Kin ni idi ti isọji yii ko fi sẹlẹ ni awọn ilu nla nla? Eyi ni opin Iwọ Oorun aye.

Bayii, idajọ ẹsẹ ti sán àrá titi de abẹ ile aye, ohun si ti bẹrẹ síí rì. Awọn ilu bii Los Angeles ati Holiwuudu, ti wọn n ri ni iwọn hi-in-ji melokan ni wakati kọọkan. Ko si ọna lati da a duro. Bẹẹni, a ti de ibi yii. Ni igbakiigba, a oo gbọ ipè ti o n pe wa sílé. Bi iwọ ba mọn eleyii,……Bayii, ki ẹnikẹni mase la oju. Sugbọn bi iwọ ba mọn ni ọkan rẹ, (mo n bi o lere). Emi ko lee mọn ọkan rẹ, afi bi Ọlọrun ba fihan fun mi. Sugbọn lati ọkan rẹ, bi iwọ ba mọn pe iwọ ko si nibi to yẹ ki o wa pẹlu Ọlọrun ati Ọrọ Rẹ, pẹlu igbagbọ, se iwọ yoo na ọwọ rẹ soke si Ọlọrun. Sọ wi pe, “Oluwa, ran mi lọwọ” Ah! Ọlọrun! Lati inu ijọ yii, ti o kun fun èrò ninu ilé ati ni ode, ọpọlọpọ lo nawọ soke, boya igba eniyan. Ẹ se fun otitọ ọkan yin.

108 Jesu Oluwa, Mase jẹ ki ọkan ki o segbe ninu wọn. Gẹgẹ bi iransẹ Rẹ, ti o duro laarin aaye ati oku, ti mo n tọka wọn si Ọrọ Ọlọrun. Emi ko lee gba wọn la. Baba, gẹgẹ bi mo ti sọ lọpọ igba ri, oòrùn n dide ni owurọ, bi o si ti n yi aye po, Ọlọrun ran an lati mu eso pọn, lati pese onjẹ ara fun wiwa laaye nipa tara. Sugbọn Ọlọrun, Iwọ wi pe, “Fun awọn to bẹru Orukọ Rẹ ni Oorun Ododo yoo dide tan pẹlu iwosan ni iyẹ apa Rẹ. Jẹ

ki Oorun Ododo ti I se Ọmọ Ọlọrun dide tan ninu ọkan awọn eniyan yii, ki itansan iwosan ti igbagbọ ninu Ọrọ naa ki o si mu wọn wa si ẹkunrẹrẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun.

Tirẹ ni wọn, Oluwa. Ni Orukọ Jesu Kristi, ati nibi ati ni ibi gbogbo ti wọn ti n gbọ mi, mo fi awọn to nawọ wọn le Ọ lọwọ fun igbala ọkan wọn. Aamin

Nibẹ ni ọkan mi ti a rapada yoo ri gba (nibo? Nibi pẹpẹ yii)

Isinmi nikọja (nipa igbagbọ, mo wo ibiti mo n lọ)

Nibi agbelebu (nibẹ ni Ọrọ naa rọ mọ)

Jẹ ogo mi titi lae

Titi ti ọkan mi ta rapada yoo ri

Isinmi nikọja odo.

Fa mi sun m'agbelebu (Eyi ni ti a kan mi magbelebu pẹlu Rẹ̀, emi ko fẹ ohun ti aye kankan. Ki n wa nibi agbelebu titi)

Orisun iwosan

Itunu fun ẹlẹsẹ

Iye fẹni nku lọ

Nibi agbelebu

Jẹ ogo mi titi

Titi n o fi goke

Si ibi isimi

109 Na ọwọ rẹ ki o bọ ẹnikan lọwọ, ki o si wi pe, "ki Ọlọrun bukun ọ, kristẹni. Njẹ ẹyin ti ẹ wa ni ori ẹrọ ibanisọrọ, ẹ bọ ara yin lọwọ, ki ẹ si sọ wi lpe, "k'Ọlọrun bukun ọ, Kristẹni.

110 Ẹ mọn pe, adagun omi wa lẹyin nibi. Ọlọrun n mu awọn eniyan kan ti o n wọnú Orukọ Kristi fun imukuro ẹsẹ rẹ, adagun omi wa nihin, asọ fun itẹbọmi wa, awọn okunrin kan ti wa ni imurasilẹ lati se e. A ki ọ kaabọ, bi iwọ ba gba Jesu lotitọ ni Olugbala ti o si gba wi pe ohun ti a waasu yi ni Otitọ

Ranti wi pe, ko si ẹnikan ninu Bibeli, tabi nibikibi saaju igbekalẹ ẹgbẹ-to-fi-idari-eniyan-rọpo-Ẹmi-Mimọ ti a pe ni Ijọ katoliiki, ti a se itẹbọmi fun ni ọna miiran ju Orukọ Jesu Kristi. Ko si ibi kan ti a ri ninu Iwe Mimọ, tabi ni iran miiran ti a tii se itẹbọmi fun ẹnikẹni sinu Ijọ Ọlọrun alaaye ni orukọ awọn apele, "Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ". Ẹkọ adamọ ijọ Katoliiki ni, kii si se ẹkọ Bibeli.

111 Alufaa ijọ Katoliiki kan fọrọ wa mi lẹnu wo, mo si bi leere eleyi. O sọ pe, "otitọ ni ohun ti o sọ yii, Sugbọn awa ni Ijọ. Alee yi ohunkohun ti a ba fẹ pada. Ọ̀wọ̀ Mimọ na wa ninu ijọ. Ọlọrun wa ninu Ijọ"

Mo wi pe, "Ọlọrun wa ninu Ọrọ Rẹ. Bi Ijọ ba si jẹ… " Ọlọrun ni Ọrọ naa. Bi Ijọ ba si lodi si Ọrọ naa, emi ko gba ijọ gbọ" Jẹ ki ọrọ gbogbo eniyan jẹ irọ, yala ti alufaa, Popu, ẹnikẹni ti ìbá à jẹ́, ki Ọrọ Ọlọrun si jẹ otitọ. Pọọlu si mu gbogbo eniyan, ọna yoo-wu ti a fi se itẹbọmi fun un. Bi a ko ba ti se ni Orukọ Jesu Kristi, ki o wa ki a tun un tẹ bọmi.

Lẹhin igba ti awọn kan ti gba Ẹmi Mimọ, Peteru wi pe, "A ha lee dẹkun omi, ni iwọn igba ti awọn wọnyi ti gba Ẹmi Mimọ" Ise Awọn Apsoteli 10:49 "Ni iwọn ti a rii pe, awọn yi ti gba Ẹmi Mimọ gẹgẹ bi awa pẹlu ti gba A ni ibẹrẹ". O si pasẹ fun wọn, "Ki ẹyin to kuro ni ihinyi, bi o tilẹ jẹ pe, ẹ ti gba Ẹmi Mimọ, Ẹ wa se itẹbọmi ni Orukọ Jesu Kristi." Nitori pe, Peteru ni a fun ni kọkọrọ Ijọba naa, ti a sọ fun un pe, "Ohunkohun ti iwọ ba de ni aye, Emi yoo dee ni Ọrun" Ki si ni kọkọrọ ma n se? O ma n si ohun kan ni. O n si awọn ijinlẹ kan.

112 Nigba ti Jesu si wi pe, "Ẹ lọ, se itẹbọmi fun wọn ni Orukọ ti Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ", O gbe e kalẹ lọna yii lati fọ oju alaigbagbọ. Wo o, kin ni idi ti Peteru ko fi mu eyi lo lẹsẹẹsẹ? O gbọdọ see. Bi a ba se itẹbọmi fun ẹnikan ni awọn apele, "Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ, ko tii se itẹbọmi rara. Ko ni orukọ kankan. Baba kii se orukọ, Ọmọ kii se orukọ, Ẹmi Mimọ kii se orukọ. Ẹmi Mimọ ni ohun ti O jẹ. O dabi, ki a pemi ni eniyan. Ẹmi Mimọ ni Baba jẹ apele baba kan ni mi. Ọmọ jẹ apele, ọmọ kan ni mi. Eniyan jẹ apele, ohun ti mo jẹ niyi sugbọn oruko mi ni William Branham. Orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ si ni Jesu Kristi. Jesu wi pe, "Mo wa ni Orukọ Baba mi" Kin ni orukọ Baba? Ọmọkunrin maa n wa ni orukọ Baba rẹ. Orukọ Baba si ni Jesu Kristi. Se

o rii? Se o ri ohun ti mo n sọ?

113 Bi mo ba sọ fun ọ pe ki o lọ gba ohun kan jade lati ile itaja lorukọ Baalẹ ilu yii. Ta ni o mọn orukọ baalẹ ilu yii? Ọrẹ mi tootọ Rich Vising. Odara, iwọ ko ni lọ sibẹ ki o wi pe, “Orukọ baalẹ ilu yii. Sugbọn, iwọ yoo sọ pe, 'Ni orukọ Richard Vising. Ẹyin eniyan Jeffersonville mọn orukọ baale naa. Idi si niyii, ti O sọ pe, ”Baba, Ọmọ, Emi Mimọ“. Ninu Rẹ ni Ọlọrun n gbe, ẹkunrẹrẹ Ẹni ti Ọlọrun I se. O wi pe, ”Ẹ tẹ wọn bọmi ni Orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ.

Peteru duro nibẹ, Pẹlu ifihan lori eyi ti a kọ ijọ le, ifihan nipa, ẹniti Jesu I se o wi pe, “Ronupiwada, olukuluku yin, ki a si tẹ yin bọmi ni orukọ Jesu Kristi” Kọkọrọ na yii l'Ọrun ati ni aye. “ko si Orukọ miiran labẹ ọrun ti a fi fun ni laarin eniyan, nipasẹ eyi ti a le fi gba wa la”

114 Kin ni idi ti ẹ fi n se itẹbọmi ni Oruko Jesu Kristi? Fun imukuro ẹsẹ ni. “Ẹnikẹni ti ẹ ba mu ẹsẹ rẹ kuro, a ti mu u kuro”. Se o rii? Sugbọn bi o ba ro wi pe ẹnikan ko yẹ, ko si tọ ki a se itẹbọmi fun un, ma see. Nigba ti o ba se e, o ti pari. Se o rii. Ohun ti mo nsọ ye ọ bi?

Mo gbọ Olugbala (Ọrọ naa) n pe mi (O n pe wa si ibi iboji)

Mo gbọ (Se iwọ ko ni ku pẹlu Mi, ki iwọ lee jinde pẹlu Mi)

Mo gbọ Olugbala mi n pe (Kin ni aye yoo sọ) gbe agbelebu rẹ, si tẹle Mi.

Bayii, bi wọ ko ba tii se itẹbọmi

Ọna to' la l'emi o rin

Ọna to la l'emi o rin

Ọna to la l'emi orin

Em' o tẹle, tẹle, titi lae.

Je ki a tẹriba

115 Ọlọrun wa ọwọn, adagun omi ti se tan. Bayii, sọrọ sinu awọn ọkan, Oluwa. Jẹ ki wọn gbọ ohun Kristi, Ọrọ naa, fun ipe wọn, ki wọn si ba a lọ de opin. “Emi yoo baa lọ ninu ọgba naa. Emi yoo ba A lọ sinu adagun omi. Emi yo gba Orukọ Rẹ. Mo fẹ jẹ ọkan lara awọn ti o n pe fun Orukọ Rẹ. Emi yoo gba Ọrọ rẹ gbọ. N o o jẹ afẹsọna olododo fun Un. Emi ki yoo fi ẹyọ Ọrọ Rẹ kan silẹ. Ohun gbogbo ti O beere, emi yoo jẹ ojulowo iyawo tooto. Ohun gbogbo ti O fẹ ki n se, ni emi yoo se. Bi Ọkọ mi to n bọ ba fẹ ki irun mi gun, emi yoo se e. Bi O ba fẹ ki n mu gbogbo ẹsọ ara yi kuro, emi yoo see. Bi O ba fẹ ki n mu gbogbo ẹsọ ara yi kuro, emi yoo se. Bi O ba sọ fun mi pe ẹmị esu ni, ẹni buburu ni, ni mo n se ifẹkufẹ pẹlu rẹ bi mo se n wọ awọn asọ to n fa ifẹkufẹ wọnyi, emi yoo bọ wọn kuro. N ko bikita ohun tẹnikẹni lee sọ, n o o bọ wọn kuro. ”O fẹ ki emi kuro ninu ẹgbẹ ti mo waa ni, ẹgbẹ awọn alaigbagbọ, emi yoo se. bi mo tilẹ ni lati se buredi mi funrara mi, tabi ohunkohun. O seleri pe, Oun ki yoo fi mi silẹ, Oun ki yoo kọ mi, emi yoo see. N o o baa lọ titi dopin. O fẹ ki n se itẹbọmi ni Orukọ Rẹ, emi yoo se. Oluwa, Iwọ seleri ninu Ọrọ Rẹ, nihin ohun ti iwọ fẹ niyii. Jẹ ki gbogbo eniyan ri Oluwa, ki wọn si fi tayọtayọ, pẹlu irẹlẹ, tẹriba fun un. Mo gbadura ni Orukọ Jesu. Aamin.

116 O jẹ ti Ọlọrun. Ki Ọlọrun mu awọn Ọrọ ti a sọ wọnyi, ki O sọ wọn di odidi, arigbamu fun ọ ni adura mi. Adagun omi naa yoo setan. Ẹnikẹni to ba fẹ wa iransẹ Ọlọrun yoo fi eyi lọ laipẹ. Ẹnikẹni to ba ti ronupiwada, to si fẹ se itẹbọmi, ni Orukọ Jesu Kristi, maa bọ taara. Ohun gbogbo ti setan. “Ohun gbogbo ti setan” ohun gbogbo ti a ba lee se lati ran ọ lọwọ ki o lee fi aye rẹ fun Ọlọrun, a wa nibi, lati see. Ki Ọlọrun bukun Ọ.

Bayii, ẹ jẹ ki a dide duro. Orin wa kekere ni, “Mo fẹran Rẹ. ”Mo fẹran Rẹ nitori pe o kọkọ fẹ mi“. Ẹ jẹ ki a kọ ọ gbogbo wa bayii.

Mo fẹran, Jesu yii (jẹ ki a gbọwọ wa soke bi a ti n kọ ọ)

Tori o kọ fẹ mi

O san gbese, igbala mi

Ni kalfari.

Pẹlu ori wa ni titẹ ba bayii, ẹ jẹ ki a kun orin naa. (Arakurin Branham bẹrẹ sii kun orin)

Ọlọrun Baba wa, saanu fun wa, awa ẹda alainilaari. Oluwa, fun wa ni okun fun isẹ ti o wa niwaju. Ran mi lọwọ Ọlọrun, ran mi lọwọ! Mo ni imọnlara pe ohun kan wa ni iwaju, Baba. Ran mi lọwọ Ọlọrun lati mọn

otitọ. Bukun awọn eniyan yii, Ọlọrun. Tọ wọn sọna, mo gbadura ni Orukọ Jesu Aamin.

Bayii, nigba ti a tẹ ori wa ba, emi yoo beere lọwọ Olusọ-agutan nihin, Arakunrin Neville, Arakunrin wa ọwọn ki o wa siwaju bayii lati sọ nkan ti o ni i sọ. Siwaju sii nipa Itẹbọmi, mo lee fi eyi lọ. Mo ro pe adagun omi naa ti setan.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7